# Irú Ẹranko-tó-Padà-Dejò

Jeffersonville, Indiana, USA
Osu Kẹsan Ọjọ 28, Ọdun 1958

1 Oluwa wa ọwọn, Ọlọrun alagbara Nlá nì, Ẹni ti O da ohun gbogbo nipa agbara Ẹmi in Rẹ̀, ti O si ti mu Jesu Kristi, Ọmọ bíbi Rẹ kansoso, Ẹni ti O ku fun awa ẹlẹsẹ, Olododo Naa fun awọn alaisododo, lati ba wa làjà padà sinu idapọ iyanu yii ti a tun ni pẹlu Ọlọrun. Gẹgẹ bi a ti kọ wa ninu Ọrọ Ọlọrun Olubukun, pé a ti ni idapọ pẹlu Rẹ̀ saaju ipilẹsẹ aye, nigba ti awọn irawọ owurọ jùmọ̀ kọrin, ti awọn ọmọ Ọlọrun si kigbe fun ayọ, saaju ki a to fi ìpìlẹ̀ aye lelẹ. Bawo ni a se mọ̀n pe kii se ni akoko kan naa ni a pa Ọdọ-Agutan nì; pe, nigba ti Ọlọrun ninu èrò nla Rẹ̀ ri wa ti a nkigbe ti a si n yọ ninu igbala wa nipasẹ Jesu?

Àti ni asalẹ yii, a ti ní àtọwò ogo nla ti Ọlọrun, eyiti a o fihan ninu wa ni ipadabọ Rẹ̀ lẹẹkeji. Gbogbo aisan ati ibanujẹ ni yoo dopin. Nigba naa ni awa yoo ni ara kan bi ara ológo Tirẹ̀, nitori awa yoo rí I bi Oun ti ri. Ni aye yi, bi a se n wo ọwọ wa ti o n hunjọ, irun ori wa n di funfun, èjìká wa n tẹ̀ba, o n ye wa pe, a jẹ ẹni kiku, a si n pada si erupẹ ti a tẹríba si bayii, nibiti a ti muwa jade. Sugbọn, Oluwa Ọlọrun, bi o ti daju pe Iwọ ni Ọlọrun, O ti se ileri pe, a o jiwa dide lẹẹkan si ni opin ọjọ́, awa si gbá á gbọ.

2 Awa fi tọ̀wọ̀tọ̀wọ̀ duro niwaju Rẹ ni asalẹ yi, awa wa pẹlu igboya nitori pe Jesu pe wa lati se bẹẹ. Kii se nitori ohun rere eyikeyi ti a ti se, nitori a ko se ohun rere kankan; sugbọn àwá wá pẹlu irẹlẹ, a n jẹwọ pe a ni ìsúra yii nitori oore-ọfẹ Rẹ ti a ti fun wa. Nitori naa, a wa n beere pe ki O bukun wa ni alẹ yi ni mimu Ọrọ naa jade wa. Nitoriti a ti kọ ọ pe “Eniyan ki yoo wa láàyè nipa akara nikan, bikose nipa gbogbo ọrọ ti o ti ẹnu Ọlọrun jade wa.”

Si jẹki ẹnu Ọlọrun sọrọ jade ni alẹ yi. Jẹ ki awọn ọrọ naa jade wa, si jẹ ki o wọ isalẹ ọkan awa olùgbọ́ lọ, ki a si kun wa pẹlu Ẹmi Rẹ ati Ìwàláàyè e Rẹ. Nitori a beere fun un ni Orukọ Jesu. Àmín.

3 Loni ati lana, ki n kuku sọ wi pe, ni alẹ ana, ati loni, a ti n sọrọ lori koko-ọrọ kan, saaju, ni kukuru, “Eredi Ti Awa Kii Fi I Se Ijọ-Ẹlẹkọ Adamọ” A si ti sọ ọ di okodoro gbangba idi ti a ko fi jẹ Ijọ-ẹlẹkọ-adamọn, ati idi rẹ ti a ko fi gbagbọ ninu awọn Ijọ-to-fi-ẹkọkẹkọ-rọpọ-Ọrọ-Ọlọrun. Nitori a ri i ninu Bibeli pe, Ọlọrun ko fi igbakanri gbe ijọ-ẹlẹkọ-adamọ kalẹ; esu ni o da a silẹ; a si ti fi idi eyi mulẹ nipasẹ bibeli. Ati bi o ti jẹ wi pe nipasẹ ijọ-ẹlẹkọ-adamọ ni ẹkọ isina fi ma a n wa. Ni bayi, a n sọ eyi lati se atunse ati lati mu apejọpọ yii wa sinu idapọ kan pẹlu Ọrọ Ọlọrun Olubukun. Eyi ni pe, a ko gbe awọn ireti wa kalẹ le ohun ti ẹgbẹ-ẹlẹkọ-adamọ sọ, tabi ohun ti ẹnikẹni ba sọ. Sugbọn a gbe e kalẹ le ohun ti Oluwa Ọlọrun ti sọ. Ọna kan soso niyii ti a fi le e tọ wa sọna ti o tọ.

4 Ni owurọ yii pẹlu, Mo mọn awọ̀n ìwé marun-un ọtọtọ ti o jade nipasẹ ijọ-ẹlẹkọ-adamọ, ti o jẹ wi pe Bibeli ko sọ bẹẹ rara, ti o jẹ wi pe awọn ijọ to-tako-ijọ-Aguda pẹlu n tẹriba fun, ti wọn si n kọni fun ẹkọ-opomulero-ijọ: ohun kan naa gẹlẹ ti iya agbere atijọ-ọ-ni: ani ijọ Aguda n waasu, awọn ẹkọ yi si wa sinu awọn ijọ-ti-wọn-tako-ijọ-Aguda. A si ntẹriba fun ohun kan naa ti o lodi si gbogbo Ọrọ Ọlọrun.

5 Ijọ-ẹlẹkọ-adamọ akọkọ; A tilẹ ri I ka ni ọsan oni, ninu itan awọn baba ti igba Nikia, nipa ijọ ni akoko Nikia. Lẹhin iku awọn Aposteli akọkọ ni awọn baba igbagbọ ti akoko Nikia wa, wọn si tẹsiwaju fun ọpọ ọdun, Ọ̀rúndúnrún ati márùn-ún-dín-lọ́gbọ̀n (325) ọdun, ki ipade igbimọ Nikia to sẹlẹ ni orile ede Faranse, nibiti wọn ti se ipade igbimọ nla Nikia. Nibẹ ni wọn ti gbe awọn ẹkọ adamo ti ijọ Aguda wọn-ọn ni kalẹ, eyi si ni awọn ijọ ti o tako ijọ Aguda pẹlu gbagbọ.

6 Gẹgẹ bi mo ti sọ ninu ẹkọ ọrọ Ọlọrun ni owurọ yii, Ninu ọkọọkan gbogbo awọn igba ijọ wọn-ọn ni, titi de igba ijọ Tẹsalonika, ẹgbẹrun kan ati abọ ẹgbẹrun ọdun tii se akoko okunkun aye, ko si igba kan ti ko sọ wipe sugbọn iwọ si gba Orukọ mi gbọ.

Sugbọn lẹhin akoko okunkun aye, wọn ko si ninu Kristi mọ. Wọn jade wa pẹlu awọn orukọ ẹgbẹ-ẹlẹkọ-adamọ. 'Ijọ Katoliiki, Luther, Wesley, Baptisti, Ijọ Prẹsibiteria, Pẹntikọsita ati bẹẹbẹẹ lọ (abb)

Sugbọn nigba ti igba ijọ naa fẹrẹẹ pari, O wipe, “Emi gbe Ilẹkun ti a si silẹ siwaju rẹ´se ẹ ri i? A si gbagbọ wi pe ni igba ijọ ti a wa ninu rẹ bayi, Igba ijọ ti ilẹkun-rẹ-si-silẹ, o wa láàárín ijadelọ igba ijọ Laodikia.

7 O si jẹ ọ̀ọ́dúnrún ati márùn-ún-dínlọ́gbọ̀n ọdun ki a to de igbimọ-ijọ-Laodikia (Nikia). Nibẹ ni wọn ti fọwọsi awọn ẹkọ adamọ wọnyi, gẹgẹ bi i fifi omi wọn-ọn ni, dida omi si ni lara, itẹbọmi eke, Ẹmi Mimọ eke, ati gbogbo nkan wọnyi. Wọn fọwọsi i.

Nigba ti Luther, ti i se Alufa ijọ Aguda jade kuro ninu ijọ na a, o jade pẹlu awọn ẹkọ isina wọn-ọn-ni. Lati ibẹ ni Zwingli ti jade, lati inu Zwingli ni Calvin ti jade, lati inu Calvin ni Wesley ti jade, bẹẹni o si ntẹsiwaju. Bẹẹni wọn si n mu awọn adamọ wọn lọwọ. Bawo ni Ọlọrun se lee dari ijọ Rẹ ni igbati wọn n tẹle awọn ọna ti Oun ko yan fun wọn lati tọ?

8 Si ranti ninu iwe ifihan17, a ri “Obinrin naa”. Bayi, awọn ọrọ wọnyi ye ni kedere. A kọ wọn sinu Bibeli,

nitori naa, mo ro pe mo lee sọ wọn. O sọ wipe, obinrin yi jẹ “pansaga” Eyi tunmọ si pe, o jẹ obinrin oniwa ibajẹ pe, o yẹ ki o jẹ aya fun ọkọ kan, ati pe o n se agbere pẹlu aye. Ati pe o tun jẹ. “IYA AWỌN AGBERE”, nitori naa, o tun ni awọn ọmọbinrin. A si ti se apejuwe eleyii nipa ibujoko rẹ lori ilẹ aye. Ati nibẹ fúnra-araàmi, mo rii ninu Iwe Mimọ, mo si ri awọn ẹkọ rẹ ati ohun gbogbo nipa rẹ. Mo gbagbọ pe Oluwa ti laa lẹsẹẹsẹ perepere, pe obinrin naa ko lee jẹ ohun miiran bikose ijọ Katoliiki. Ko lee yatọ rara si eleyi. Ki si ni awọn ọmọ ti o bi? Awọn ijọ ti wọn jẹ alatako ijọ aguda. Bẹẹ gẹlẹ ni o se.

Obinrin naa si gbe ago waini awọn agbere rẹ lọwọ, o si n fifun awọn ọba aye. O si jẹ alakoso kaakiri gbogbo aye, ti a ba nsọrọ nipa ti ẹmi. Otitọ ni eyi gẹlẹ. Ko tun si omiran.

9 Woo, ẹ jẹ ki a pada lọ si iwe Danięli ki a si lọ mu ere naa. Wo ere naa. Ori rẹ jẹ wura, ti i se ijọba Babiloni, lẹhin naa fadaka jẹ ijọba Midia ati Pasia. Alẹkisandira Nla ni ati bẹbẹlọ, Ijọba giriki, lẹhin naa ni ijọba Ilẹ-Ọba-Nla ti Roomu, ti Ila oorun ati Iwọ oorun Romu si jẹ ẹsẹ ere naa mejeji.

Si kiyesii, ninu ijọba nla mẹwa yi, ti wọn wa pẹlu iwo mẹwa ti a nsọrọ nipa rẹ lowurọ yi, ninu ọkọọkan awọn ijọba mẹwa ti yoo dide, irin ati amọ̀n darapọ mọ ara wọn. Irin naa si wa lati awọn ẹsẹ rẹ, tii se Roomu. A si ri ilana ati iwa Roomu ninu orilẹede gbogbo ti o wa labẹ ọrun nipasẹ ijọ Aguda. Otitọ niyi gẹlẹ. Wọn ko si le e di ọkan nibikibi. Wọn si n se igbeyawo pẹlu ara wọn laarin ẹgbẹ mẹjeeji. Bibeli sọ wipe wọn yoo se bẹ ẹ.

10 Si kiyesi wọn loni bi ọmọkunrin rẹ ba n ba ọmọ ijọ Aguda rin, nigba ti wọn ba lọ lati se igbeyawo, wọn yoo kan nipa pe ẹ gbọdọ tọ awọn ọmọ wọn dagba ni ilana ijọ Aguda. Se o rii, iba a se ọkọ ni tabi iyawo lo jẹ ọmọ ijọ Aguda. Erongba wọn ni lati din agbara ijọ ti kii se tiwọn ku.

Sugbọn kin ni o jẹ gan an? Bibeli sọ pe ijọ agbere ni gbogbo rẹ lapapọ. Ki ni o wa fẹ se bayi? Otitọ ni yii. Bi a ba nilati bẹ ẹ̀sẹ̀ awọn eniyan naa wo….. A pada lọ si inu Ditaronomi, a si fihan wa pe, ọmọ ale ko lee wọ ile ijọsin Oluwa fun iran mẹrinla. Eyi wà ninu ofin. Kiristi si wa mu ofin gbooro si. Bawo ni yo se wa le to bayii?

11 Kin ni o si n sẹlẹ si awọn eleyi? Kin ni o se awọn obinrin ti o nwọsọ ibajẹ loju popo loni, awọn obinrin kekere ti o n mu siga yi, ti n wọ asọ ti ko bo ihoho ara, ti wọn ngẹ irun ori wọn abb? Kin ni o n da wọn laamu? O jẹ nitori wi pe iya wọn huwa bẹẹ. O jẹ ibẹ-ẹsẹ-baba-wo lati iran kan de iran miran. Ohun to jẹ niyii. Ki si ni abayọri rẹ̀. A ti wa de ibi wi pe, ògédé-àdàlù-ẹ̀sẹ̀-rírùn ni o sẹ́ kù.

12 Idi ni yii ti Ọlọrun fi gbe Russia dide pẹlu àdó-olóró-abúgbàmù kan lati fi paarẹ, gẹgẹ bi ikun omi ti paye rẹ nigba aye Noa, nigba ti Ọlọrun gbe awọn ìkúùkù dide. Dajudaju, o ti se bẹẹ. Bibeli si wi bẹ ẹ. Russia, orilẹ ede ti ko gba Ọlọrun gbọ, kan n se isẹ gẹgẹ bi ohun elo lọwọ Ọlọrun Olodumare. Gẹgẹ bi Ọba Nebukadinesari se sẹgun Israeli nitori wi pe wọn kuna lati ba Ọlọrun rin, bẹ gẹlẹ ni Russia se ndide lati “gbẹsan awọn eniyan mimọ” lara ijọ Aguda nitori ẹjẹ awọn eniyan mimọ ti o ti ta silẹ. Bibeli sọ bẹ. Yio pa gbogbo rẹ run.

13 Woo na, bi iya wọn ba jẹ alájótà, iya iya wọn ati iya rẹ jẹ obinrin to nwọsọ to fi ihoho ara han, kini ohun na jẹ loni? Onijo taka-n-sufe to wọsọ ti ko bo ihoho ara. Kini awọn ọmọ rẹ yio jẹ? Iwọ wi pe, “se Ọlọrun n se iyẹn bi? Bẹẹ ni. Ọlọrun n bẹ ẹsẹ awọn obi wo lara awọn ọmọ lati iran de iran, ani titi de iran kẹrinla. Bi Kristi ba si wa mu ofin gbooro sii, ki a sọ wipe ọgọrun iran tabi ẹẹdẹgbẹta iran. Tori ki ni? O wipe ”Ẹyin ti gbọ bi awọn ti igbani ti wi pe. “Iwọ ko gbọdọ paniyan. Emi wi fun ọ pe ”Bi iwọ ba binu si arakunrin rẹ lai ni idi, iwọ ti paniyan na. Ẹ ti gbọ ti awọn ara igba a ni wipe, “Iwọ kọ gbọdọ se pansaga”, sugbọn Emi wi fun ọ pe ẹniti o ba wo obinrin kan, ti o si se ifẹkufẹ sii ni ọkan rẹ, o ti se pansaga pẹlu rẹ na. O sọ di gbígbóòrò. Ki ni gbigbooro jẹ? O sọ di titobi ni ilọpo pupọ. Bi o ba jẹ iran mẹrinla labẹ ofin, melomelo ju bẹẹ ni yio jẹ loni?.

14 Awọn ọkunrin, ọdọkunrin, agba wọn ati awọn ọkunrin to ni iyawo, kò bọla fun ẹjẹ igbeyawo mọn. Wọn kan n mu obinrin pẹlu wọn nibikibi bi aja. Aja paapaa tilẹ ni ọwọ ati itiju ju awọn eniyan kan. Mo mọn pe iyẹn le pupo, ootọ ni.

Tori kin ni? Awọn ijọ si n ba gbogbo rẹ lọ lai sọ ohunkohun nipa rẹ. Kin ni idi rẹ? Wọn n se gẹgẹ bi awọn iya wọn ti se. Awọn ijọ jogun rẹ ni. Nitori pe ijọ naa ati ijọ ti-o-tako-ijọ-Aguda jade lati inu ijọ Aguda, a bẹ ẹ̀sẹ̀ ìjọ Aguda naa wo lára awọn alatako-ijọ-Aguda. Dajudaju bẹẹ lo ri, nitori naa, ìkòkò kòleè pe ohun ìdáná miiran ni onídòtín. Otitọ pọ́nbélé ni.

15 Bayi, a rii daju ninu Iwe mimọ wi pe………. Emi kosiri iwe kankan lori tabili ni asalẹ yii. Mo sọ wi pe, Fi ibikan han mi ni ibiti Ọlọrun ti gbe ijọ-ẹlẹkọ-adamọ kalẹ. Fi ibikan han mi ni ibiti Ọlọrun ti fi isẹ oniwaasu le obinrin lọwọ. Fi ibikan han mi ni ibiti Ọlọrun ti fi lọlẹ lati máa bu omi wọ́n ni. Fi ibikan han mi ni ibiti Ọlọrun ti fi lọ́lẹ̀ lati máa da omi lé eniyan lori. Fi ibikan han fun mi ni ibiti Ọlọrun wi pe ki a se itẹbọmi ni orukọ Baba, Ọmọ, Ẹmi mimọ. Wa awọn nkan wọnyi. Sibẹ, a n se wọn ni gbogbo igba. Eyi si kan gbogbo ijọ.

16 Bayi, mo sọ fun yin idi ti a ko fi lee jẹ Baptisti nitori pe awa gbagbọ ni sise itẹbọmi ni Orukọ Jesu Kristi

Oluwa. Ko si ẹlomiran ninu Bibeli ti a se itẹbọmi fun ni ọna miiran. Iwọ fi ibi kan han mi ni ibiti a ti se itẹbọmi fun ẹnikẹni ni orukọ Baba, Ọmọ, Ẹmi Mimọ. Bi o ba leese emi yoo kawọ soke ni ìtúúbá, n oo si wi pe mo jẹ wolii eke.

Bi Bibeli ba si sọ wi pe, a gbọdọ se itẹbọmi ni orukọ Jesu Kristi, eyi jasi pe, a gbọdọ se bi o ti wi yẹn. Pọọlu pase fun wọn pe ki a tun wọn tẹbọmi lẹẹkan si.

Bi o ti wu ki wọn ti se itẹbọmi tẹlẹ ri, wọn ni lati wa, ki wọn si tun un se lẹẹkansi. Johanu onitẹbọmi, ẹni ti o tẹ Jesu Kristi bọmi ni o se itẹbọmi fun wọn ni igba akọkọ. Pọọlu sọ fun wọn pe, eyii ni ko lee sisẹ mọ, o ni lati wa ki osi se itẹbọmi lẹẹkansi. Wọn si nilati see ki wọn to lee gba Ẹmi Mimọ. Eto Ọlọrun ni. Mo lee lọ jinlẹ diẹ si ni asalẹ yi. Nitori kin ni? Jesu npa Ọ̀rọ̀ Rẹ mọ. Njẹ iwọ gba eyi gbọ bi? Bayi, o fẹrẹ lee jẹ gbogbo yin lo wa ninu isin lowurọ yii. Sugbọn mo tun fẹ tẹnu mọọ diẹ si.

17 Kin ni idi ti Pọọlu fi pasẹ yi lẹhin ti wọn ti se itẹbọmi? Pọọlu wipe,“Bi Angeli kan paapaa ba wa waasu ohun miiran ti o yatọ si eleyi, je ki o di ẹni ifibu” Nisisinyi, o wipe, “Awa ni Imọlẹ tuntun lorii rẹ” Bẹẹkọ iwọ ko ni imọlẹ tuntun kan. Ẹ ko nilo imọlẹ tuntun. O nilo lati rin ninu Imọlẹ ti Ọlọrun ti pese silẹ, o pari.

18 Kiyesi eleyi bayii, bi o ti rọrun to. Nigba ti wọn sọkalẹ lati ori oke ipalarada, Jesu wi fun awọn ọmọ Rẹ pe, “Ta ni awọn eniyan nfi Emi Ọmọ Eniyan pe?”

Ọkan wi pe Iwọ ni Mose, tabi Elija, ọkan ninu awọn wolii.

O wipe “Tani ẹyin fi mi pe?”

Peteru wi pe, “Iwọ ni Kristi, Ọmọ Ọlọrun Alaaye”

O wipe, “Olubukun fun ni iwọ Simoni ọmọ Jona, nitori ẹran ara ati ẹjẹ kọ ni o fi eyi han fun ọ” Se o rii, kò wá nipasẹ, ile ẹkọ Bibeli, kò wá nipasẹ ẹgbẹ ti o fi ẹkọ-eniyan-rọpọ-Ọrọ Ọlọrun.

Ẹran ara ati ẹjẹ kò fi eyi han fun ọ. Kii se ile Iwe Ẹsin ni o ti kọ ọ. Sugbọn Baba mi ti n bẹ ni Ọrun, ni o fi I han fun ọ, ati ni ori Apata yi ni Emi yoo kọ ijọ Mi le, ẹnu ibode ọrun apaadi ko si lee borii Rẹ“. Ifihan-Ẹmi ti Ẹni ti Oun I se.

Kiyesi, “Emi si wi pe, iwọ ni Peteru. Emi yoo si fun ọ ni awọn kọkọrọ Ijọba naa, ohunkohun ti iwọ batu silẹ ni aye, Emi yoo tuu silẹ ni ọrun. Bayi, o ni lati mu Ọrọ Rẹ sẹ, bikose bẹẹ Oun kii se Ọlọrun.

19 Bayi, nigba ti O se eyi, lẹyin ọjọ diẹ, a kan An mọ agbelebu, O jinde, O si goke lọ si Ọrun, Peteru sì sí ilẹkun Ihinrere ni ọjọ Pẹntikọsti. Njẹ o see bi? Dajudaju, o see. Bayii kiyesi, nigbati o fee…………..

Awọn eniyan n se ẹlẹya nitori pe a kun wọn pẹlu Ẹmi Mimọ. A pe wọn ni aladamọ, gbarayilẹ-mimọ, tabi iru awọn orukọ bẹẹ. Wọn tilẹ fi wọn rẹrin, wọn si wi pe, “Awọn wọnyi ti mu ọtin waini ni amupara”.

Peteru si dide laaarin wọn, o gbe ohun rẹ soke o wipe “Ẹyin ọkunrin ati ara, ẹ fi eti si mi. Ẹ fi eti silẹ si ọrọ mi, ẹ si gbọ ohun mi. Awọn wọnyi ko mu ọtin yo gẹgẹ bi ẹ ti ro, eyi saa ni wakati kẹta ọjọ. Sugbọn eyi ni eyii ni ti a ti ẹnu wolii Joẹli sọ wi pe ”yoo si se ni ikẹhin ọjọ, Emi yoo tu Ẹmi Mi jade, ati ohun ti yoo se lori awọn ọmọkunrin Rẹ ati awọn ọmọbirin Rẹ ati awọn ọmọ ọdọ Rẹ obinrin ati bẹẹbẹẹ lọ ni ọjọ naa“.

20 Nigba ti wọn bẹrẹ si gbọ eyi, ọkan wọn gbọgbẹ ninu wọn. Nitori wọn gbọ ọrọ ọkunrin kan ti ko lee ka iwe, sugbọn wọn kiyesii pe, o ni ohun kan ninu rẹ. Ina Ẹmi Mimọ ni. Se ẹnikan lee daa lẹkun bii? Kò seése, yoo kan dabi igba ti eniyan ba fẹ pa ina ti o njo ni ilẹ gbigbẹ kan nigba ti atẹgun lile nfẹ. O ko leepa ina naa. A kun-un pẹlu ina Ẹmi Mimọ. Kin ni o tun se bayi?

Wọn wi pe, “o dara, ẹyin okunrirn ati ara, kin ni ki awa ki o se ki a le la”?

Kiyesi i bayii, Peteru, iwọ ni o ni kọkọrọ Ijọba Ọlọrun lọwọ. Se o rii?

Nigba ti Jesu jinde ni ọjọ kẹta, Oun ko ni kọkọrọ ijọba ọrun lọwọ. Njẹ iwọ mọn eyi bi? O wi pe, “Emi ni kọkọrọ iku ati ipo oku” ko sọ pe Oun ni kọkọrọ Ijọba Ọlọrun; nitori O ti fi wọn le Peteru lọwọ.

21 Bayii, O wi pe “Peteru, ohunkohun ti iwọ batu silẹ laye, Emi yoo tu u silẹ lọrun. Ohun ti iwọ ba de ni aye, Emi yoo de e ni Ọrun”. Bayii, Peteru duro pẹlu awọn kọkọrọ naa lati si ilẹkun Ibukun yii fun aye. O duro ti oun ti awọn kọkọrọ naa lọwọ rẹ. Awọn eniyan si nbere wi pe “kin ni ki awa ki ose ki a lee ri igbala. Bayii, ohunkohun ti Aposteli yi ba sọ pe ki wọn se, Ọlọrun ní lati fi ọwọ sii ni ọrun, niwọn igba ti O ti fun un ni asẹ naa.

Bayi, Peteru wi pe, “Ẹ ronupiwada, olukuluku yin ki a si tẹ yin bọmi ni Oruko Jesu Kristi fun imukuro ẹsẹ yin, ”ẹyin yoo si gba Ẹbun Ẹmi Mimọ“ Se bẹẹ ni ori? Idi si ni yi ti awọn kọkọrọ naa si ilẹkun ni ọrun yatọ si

oruko k'orukọ miiran, ọna miiran, ohunkohun to yatọ. O si I ni aye, O si I ni Ọrun, lai jẹ bẹẹ, Jesu ko pa Ọrọ Rẹ mọ si peteru. Ibi gbogbo ti wọn si ti se itẹbọmi lẹyin naa ninu Bibeli, a se itẹbọmi ni Orukọ Jesu Kristi. Awọn ti wọn si ti se itẹbọmi saaju eleyi ni lati pada wa ki a si tun un se ni Orukọ Jesu Kristi lati lee gba Ẹmi Mimọ. Otitọ ni eleyi, o si n sẹlẹ bẹẹ gẹgẹ.

22 Nitori naa, bi a ba nkọni ni itẹbọmi ni orukọ Baba, Ọmọ, ati Ẹmi Mimọ, isọtẹlẹ eke ni. Bayi, emi ko fẹ sẹ yin, sugbọn mo ni lati kan an wọlẹ ki ijọ yii lee mọn otitọ. A kò kórajọ pọ̀ sibi gẹgẹbi ẹgbẹ kan ti ko mọn ohun ti wọn n se. A mọn ibi ti a duro si ninu Ọrọ Ọlọrun. Se o rii, a mọn ọn. Mo pe ẹnikẹni ni ija pe ki o fihan mi ibi ti a ti se itẹbọmi fun ẹnikankan ni orukọ “Baba, Ọmọ, Ẹmi Mimọ”. Nisisiyi, se iwọ yoo feti si isọtẹlẹ eke tabi iwọ yoo feti si Otitọ? Wa inu Iwe Mimọ. Ó kù sọ́wọ́ọ̀ rẹ.

Fihan mi ibiti ẹnikan ninu Bibeli ti gbe ijọ kan kalẹ gẹgẹ bi ijọ-to-fi-ẹkọ-eniyan-rọpo-Ọrọ-Ọlọrun. Fihan mi ninu Bibeli nibiti a ti yan obinrin kan si isẹ-iriju-iwaasu. Fihan mi ninu Bibeli ni ibiti gbogbo nkan wọnyi ti a ti nsọrọ nipa rẹ, ti a ti fọwọ sii ninu Bibeli. Wọn ko si nibẹ. Sọ ibi kan fun mi.

23 O n lọ si ijọ-ẹlẹkọ-adamọ………Odara, nigbati Mẹtọdisti dide, wọn waasu isọdi-mimọ. Eyi dara. Sugbọn, nigba ti wọn se eyi tan, wọn sọra wọn di ijọ-ẹlẹkọ-adamọ, o ba pari sibẹ. Idi niyi ti Bibeli fi wi pe “Iwọ ni orukọ kan”

O wi pe, kristẹni ni mi.

Ijọ-ẹlẹkọ-adamọ wo ni tirẹ?

Iwọ dahun wi pe, “Mo jẹ ijọ Mẹtọdisti. Tori kin ni? Asẹwo ni ọ nigba naa. ”Mo jẹ Baptisti,“ Asẹwo. ”Ijọ afede-ajeji-sẹri-Ẹmi Mimọ ni tirẹ“ asẹwo ni ọ. Dukia ijọ yẹn ni iwọ i se.

O yẹ ki o jẹ ti Kristi. Iwọ ko ni ojuse kan lati ma a pe ara rẹ ni ọmọ ijọ “Mẹtọdisti,” “Baptisti.” Bi o ba jẹ kristẹni, o jẹ kristẹni ni ọkan.

24 Olukuluku awọn ijọ aladamọ yii ni o lee ni ọmọ Ọlọrun tootọ, bẹẹ ni. Sugbọn nigba ti o ba ro wipe iwọ nlọ si ọrun nitoripe o jẹ ọmọ ijọ Mẹtọdisti, Baptisti , abb, o kuna. Idi si niyi ti a fi takete si ohun naa. Kilode ti Baptisti ko fi lee rii?

Mo beere lọwọ ọkunrin Baptisti kan ti o n kọ àpilẹ̀kọ lori iwadi kan. O wi pe, “Ohun kan soso ti awa ni lodi si ọ ni pe, o nkọwọ rin pẹlu awọn ijọ a fede-ajeji sẹri-Ẹmi Mimọ”.

Mo wi pe, “Ẹyin wo ni ”awa?“”

O dahun, “Awa Ijọ Metodisti”

Mo wi pe, “O dara, jẹ ki n sọ ohun ti mo fẹ ki a se. Emi yo o wa si ilu rẹ, iwọ jẹ ki Ijọ Baptisti se agba-tẹru ipade naa.”

O wi pe, “Ah! dajudaju, awa ko le se iyẹn”

Mo wi pe, “Ohun ti mo ro gan an niyẹn.” Mo fara mọn awọn a fede-ajeji-sẹri-Ẹmi Mimọ nitori pe wọn gbagbọ ninu ohun ti mo nse. Otitọ ni yẹn. Wọ́n sùùrù bò ó. Awọn ni wọn n jẹ anfaani rẹ.

Ẹyin melo ni ẹ ka apilẹkọ yẹn ninu iwe iroyin àtìgbàdégbà “Life”, laipẹ yi nipa Ijọ ti o fede-ajeji-sẹri-Ẹmi Mimọ? O jẹ ọkan ninu kà-yéé-fì to gajulọ ni iran yi. Wọnni awọn ti wọn yi pada, to si darapọ mọ wọn, pọ ju ti apapọ gbogbo ijọ ti o ku. Tori kin ni? Pẹlu awọn ẹko isina wọn, sibẹ Ọlọrun n mu wọn tẹsiwaju nitori pe, wọn gba Otitọ gbọ, wọn si nsisẹ pẹlu u Rẹ̀. Otitọ ni.

25 Sugbọn kin ni a n se bayii? Se ẹ rii? Idi rẹ niyi ti a ko jẹ ijọ-ẹlẹkọ-adamọ. Bi o si ti daju pe Ijọ Pẹntikọsti di Ijọ to-fẹkọ-adamọ-rọpo-Ọrọ Ọlọrun……… Nigbati Ẹmi Mimọ kọkọ da le awọn ijọ afede-ajeji-sẹri-Ẹmi Mimọ, ni Ogoji ọdun sẹyin, wọn bẹrẹ si fi ede tuntun sọrọ, tii se ọkan ninu awọn ẹbun Ẹmi Mimọ. Ohun ni eyi ti o kere julọ; gẹgẹbi Pọọlu Mimọ ti kọni, ifede-miiran sọrọ ni o kere julọ. Ni kete ti ẹbun yi de, wọn wi pe, “A! Ọwọwa ti tẹ Ẹ wayi” wọn si sọ ara wọn di ijọ-ẹlẹkọ-adamọ, “Igbimọ Apapọ Naa.” Tii se “Asembili Ọlọrun”(Assemblies of God). Nisisiyi, wọn wipe, “Ah! Ko si ẹni ti o ti ri I gba ayafi bi o ba sọrọ ni ede ajeji.” Ọlọrun si tẹsiwaju taara, O fi wọn silẹ si ibi ti wọn wa. Dajudaju, bẹẹ ni.

26 Nigba naa, awọn ẹlẹkọ-Ọlọrun-jẹ-ọkan-bi-ika-ọwọ-kan(Oneness) de, Wọn sawari itẹbọmi ni Orukọ Jesu. Wọn wi pe, “Ah! Ọwọ wa Tẹ Ẹ”. Wọn di ẹgbẹ-to-fi-eniyan-se-adari-dipo-Ẹmi Mimọ. Kin ni wọn se? Ọlọrun kan jade lọ kuro laaarin wọn, O si fi wọn silẹ sibẹ. Ó wà fún “Ẹnikẹni, ti o ba fẹ, jẹ ki o wa”

Se o rii, awọn ẹlẹkọ Ọlọrun-jẹ-ọkan-soso bi-ika-ọwọ-kan ko lee lọ si Ijọ Asẹnbili. Awọn ọmọ Asẹmbili ko

lee lọ si Ijọ-Ọlọrun-jẹ-ọkan. Mo ti ba diẹ sọrọ ninu awọn ọkunrin wọn ti o dara julọ, Ọgbẹni Goss ati Dr. Pope, ati awọn miiran. Awọn ọkunrin ti o jẹ ọtọkulu laarin …… Mo joko pẹlu wọn. Mo wi pe, “Bawo ni ẹ se lee maa kọ ẹkọ ifi-ede-ajeji-sẹri-Ẹmi Mimọ, gẹgẹbi onimọ Bibeli?

Wọn wi pe, “O dara, Arakunrin Branham”, Awọn bii meji tabi mẹta ninu wọn sọ otitọ gan an. Wọn wi pe, “Awa mọn pe ẹko yii kii se otitọ, sugbọn kin ni a lee se? Bi a ba sọ ohunkohun lodi sii bayi, ah!, yoo da gbogbo agbekalẹ eto naa ru” Dajudaju, bẹẹni, ẹ kò ní jẹ́ Bisọọbu tabi Alakoso Agba Ijọ mọ́n. Ilepa wọn gan an ni yẹn.

27 Arakunrin, o tẹ mi lọrun ki n kuku ni ile isin kekere kan ni kọrọ kan tabi ki n maa waasu labẹ igi, ki n si ni Otitọ, dajudaju, ki nsi mọn wi pe, mo nsọ Otitọ. Eniyan nfẹ Otitọ. O si di dandan gbọn fun ọ gẹgẹbi kristẹni, lati maa tan akọsilẹ Otitọ kiri. Ọlọrun yoo mu ọ jihin fun un.

Nigba naa, lori nkan wọnyi, bi iwọ ko ba ti se itẹbọmi ni Orukọ Jesu Kristi, ti o ko si tii se nkan wọnyi, ti o ko si tii gba Ẹmi Mimọ……

O wipe, “Ah! Mo ti fede miiran sọrọ”. Iyẹn ko jasi pe o ti ni Ẹmi Mimọ. Mo ti ri awọn ajẹ, oso, ẹmi esu, ati ohun gbogbo miiran ti wọn fede ajeji sọrọ. Dajudaju. Wọn ko ni Ẹmi Mimọ, iwọ naa si mọn bẹẹ. Wọn mu ẹjẹ lati inu egungun agbari eniyan, wọn si jo, wọn kepe esu, wọn si sọrọ ni ede ajeji. Dajudaju, bẹẹ ni. Wọn ko ni Ẹmi Mimọ. Nitori naa, wi pe o fi ede miiran sọrọ ko jasi pe o ti gba A. Ọna kan soso ti iwọ fi mọ pe o ni I, nigba ti ẹmi rẹ ba njẹri pẹlu Ẹmi Rẹ̀, ti awọn eso Ẹmi ntẹle ọ: Ifẹ, igbagbọ, ayọ, alaafia, ifarada, iwa rere, iwa irẹlẹ, iwa pẹlẹ. Nigba naa ni o mọn wi pe o ti ni Ẹmi Mimọ. O njẹri Ara Rẹ̀.

28 Bayi, nigba ti iwọ ba n gbiyanju lati simi le, jíjẹ́ ọmọ Ijọ Asẹnbili tabi Ijọ Baptisti, tabi Ijọ Pirẹsibiteria; se o ri ohun ti o n se? O n gba orukọ agbere ni yẹn. Otitọ gẹlẹ niyi. Jade kuro ninu nkan yẹn. Kuro ninu rẹ̀. Emi ko sọ wi pe ki o fi ijọ rẹ silẹ tabi ohun kan bẹẹ; iwọ se ohun to ba wu ọ nipa iyẹn. Sugbọn kuro ninu gbi-gbẹkẹle “Ah! Mo jẹ Ijọ Pirẹsibiteríà. Awa ko gbagbọ ninu isẹ iyanu loni”. Kin ni idi ti iwọ ko fi gbagbọ ninu rẹ? Bibeli kọ ọ. “Ah! Mo jẹ ọmọ 'Ijọ ti Kristi': Wọn si sọ wi pe, ọjọ sise isẹ iyanu ti kọja”. Wolii eke ni wọn. Mo lee fi han ọ, ibi ti Jesu Kristi ti fi Agbara fun Ijọ, lati wo alaisan san, lati ji oku dide, ki wọn si le awọn ẹmi esu jade. Mo pe ẹnikẹni ni ija lati fi Ọrọ Ọlọrun kan han mi ninu Bibeli nibi ti O ti gba Agbara naa kuro lọwọ Ijọ.

Kin ni o mu u kuro? Ẹkọ adamọ tirẹ ni. Otitọ ni yii. Kii se Ọrọ Ọlọrun lo mu u kuro. Ẹmi Ọlọrun si n sisẹ naa lọ sibẹ. O n tẹsiwaju bẹẹ gẹgẹ. Yoo si maa se titi lai. Idi niyẹn ti awa ko se fi ẹkọ-eniyan dipo-Ọrọ-Ọlọrun; “Wọn ni ifarahan iwa bi Ọlọrun, wọn si nsẹ́ Agbara Rẹ; ”Ẹ yara yin kuro ninu ẹgbẹ bẹẹ“. A ko gbagbọ ninu ohun yẹn.

29 Bayi, bawo ni o se bẹrẹ rara? A ni lati yara ki a si wọ inu rẹ̀ kiakia bi a ba sele e yara to; bi o tilẹ se bẹrẹ gan an. A ni ọpọlọpọ iwe Mimo ti a kọ silẹ bayi nipa Ẹmi Mimọ.

Ohun miiran ni wi pe, a se ipenija kan ni alẹ́ ana, nipa “ifarada ti awọn eniyan Mimọ” kii se ni ọna ti Ijọ Baptisti fi gba a gbọ. Rara o. Mo tako “igbagbọ bi a ba ti gba ọ la, a ti gba ọ la dopin, lai bi kita igbe aye ti o gbe, yala o ba Ọrọ Ọlọrun mu tabi ko baa mu” (Ẹkọ Kalfini). Dajudaju mo tako Ijọ Pirẹsibiteria. Mo tako awọn Mẹtọdisti lori ẹko Àmíníánì wọn (isẹẹ rẹ ni a o o fi gba ọ la, ko si ore ọfẹ rara). Bẹẹ ni, sugbọn awọn mejeeji ni o ni otitọ diẹ, sugbọn o nilati mu u pade ara wọn ni Ihinyi nibiti o ti jẹ otitọ. Nigba ti o ba eyikeyi lọ ninu wọn patapata, iwo yo o di digbolugi tabi ẹhanna pẹluu rẹ̀. dajudaju, bẹẹ ni.

30 Awọn ijọ Baptisti lee wa, ki wọn se itẹbọmi fun wọn nipa riri wọn bọmi. Oniwaasu a si se itẹbọmi fun wọn, mẹsan ninu mẹwa wọn yoo mu siga, wọn yoo ta kaadi, wọn yoo sere bónkò ni gbogbo oru, wọn yoo kaakiri, se isowo ti ko tọ, awọn obinrin wọn n wọ asọ penpe ti ko bo itan, wọn n kaakiri bẹẹ, loju pópó, wọn n ge irun wọn, wọn nmu siga, wọn a maa sọrọkọrọ, wọn a lọ si apejẹ ẹgbẹ obinrin kan ti wọn a maa sẹ́fẹ̀ ti ko tọ. Se o pe iyẹn ni igbe aye kristẹni? O si pee ni, ìfi-ni-pamọ́-sínú-ìgbàlà-Àìnípẹ̀kun? Ọrun apaadi ni o morile bi o se n lọ yẹn. O ko lee gbadun ara a rẹ ni Ọrun lọnakana. Rara, o ko lee se. iyẹn kii se Ìpamọ́-Ìgbàlà-fún-Àìnípẹ̀kun.

Sugbọn nigba ti a ba tun eniyan bi nipa Ẹmi Mimọ……. Ati ẹyin A-fèdè-àjèjì-sẹ̀rí-Ẹmi-Mimọ, nitori pe ẹ lee fò sókè, sódò, ki ẹ sọ ede ajeji, sa soke, sodo laarin ile-isin, iyẹn ko jasi pe ẹ ni Ìpamọ́-Ìgbàlà-Àìnípẹ̀kun. Laelae, ma se jẹ́ ki iyẹn wa sinu èrò rẹ. Rara kii se bẹẹ. Nitori pe, iwọ pẹlu mọn pe, igbe aye rẹ n jẹ ọ lẹri wi pe, iwọ ko tọ pẹlu Ọlọrun iyẹn kii tii se Ìpamọ́-Ìyè-Àìnípẹ̀kun.

31 Sugbọn mo fẹ bèèrè ohun kan. Njẹ Ìpamọ́-ìgbàlà-Àìnípẹ̀kun wa bi? Bibeli sọ pe O wa. Bibeli wi pe, a ti kọ awọn orukọ wa sinu Iwe Iye ti Ọdọ-agutan saaju ki aye to bẹrẹ rara. Gẹgẹ bi mo ti sọ ni owurọ yii, mo tun sọ bayi lẹ́ẹ̀kan si. Ọkunrin ti o kọ orin naa “Orukọ tuntun kan wa ti a kọ sinu Ogo lalẹ yii, orukọ mi si ni”, èrò-ùngbà rẹ̀ dara, sugbọn oun kuna, bi a ba gbe e le òsùwọ̀n Iwe Mimọ. A ko kọ orukọ rẹ silẹ ni alẹ ọjọ ti a gba ọ la. Orukọ rẹ, gẹgẹ bi Bibeli ti wi, ni ibamu pẹlu Iwe Ifihan 13, 17 ati bẹẹbẹẹ lọ, “a ti kọ ọ silẹ ki aye to bẹrẹ

rara; a si ti pa Jesu Kristi saaju ipilẹṣẹ aye”.

32 Bawo ni Ọlọrun Ailopin, ti O si mọ opin lati ibẹrẹ wa. Bawo ni Ọlọrun ti ko lopin se lee gba ẹṣẹ laaye lati wa si aye, bi Oun ko ba ni idi fun un?

Lati fi ẹṣẹ̀ awọn nkan ti a ti sọ mulẹ. Ewo ni o saaju lati wà, se Olugbala ni tabi ẹlẹṣẹ? [Enikan ninu ipejọpọ wi pe, “Olugbala”] Dajudaju Olugbala ni. Ewo ni o lagbara ju, Olugbala kan tabi ẹlẹṣẹ? Bi Olugbala ba lee mu ẹṣẹ kuro, Oun ni o lagbara ju ẹṣẹ naa lọ.

O dara, eese ti Oun fi gba a laaye lati wa ni ibẹrẹ? Lati fihan wi pe, Oun jẹ Olugbala ni.

Ewo ni o lagbara ju, Olùwòsàn kan tabi aisan? [enikan dahun pe“Oluwosan”] Oluwosan. Nigba naa, ki ni idi ti O fi jẹ ki aisan wa? Lati lee fihan wi pe Oun jẹ Oluwosan. Inu mi dun tayọ bayii. Bẹẹ ni. Á à à! Awọn akayẹ Rẹ niwọn yẹn. Idi ni yẹn ti O fi n gba wahala láàyè. Idi ni yẹn ti o fi n gba ibanujẹ laaye, lati fihan pe Oun ní ayọ. Dajudaju, bẹẹ lo ri. Idi niyi ti a fi ni òru, lati fi dani loju pe, ọsan wa. Idi niyi ti a fi ni ibinu, lati fi alaafia han. Bẹẹni, ọ̀tún ati òsì ni. Ah! Òun jẹ́ iyanu.

33 Wayi o, bawo ni ó se bẹrẹ? A o o wọ inu rẹ̀ taarata, bi a ba se le se ni kánmá-kánmá to, ki emi ma ba da yin duro fun gbogbo oru. Wayi o, ohun gbogbo ni o ni lati ni ìbẹ̀rẹ̀. Mo si fẹ bèèrè ohun kan lọwọ yin bayi, eyi lee…… Iwọ saa fi eyi pamọ si ookan ayaa rẹ. O ko ni lati gba eleyi pọ mọn awọn ohun ti o wọpọ. Sugbọn feti si eleyi. Bi iwọ ba jẹ Ẹda Ainipẹkun, a jẹ wi pe iwọ ko ni ibẹrẹ, bẹẹni iwọ ko lee ni opin. Nitori pe, Ainipẹkun tumọ si “Ohun ti ko ni ibẹrẹ tabi opin”. Se iwọ ko ranti ni? Mo sọ ni owuro yii, bi o ti jẹ wi pe, Mẹlkisedeki, nigba ti O pade Abraham ti o n pada bọ wa lati ibi ti o ti pa awọn ọba naa. Bibeli si sọ ninu Heberu 7 wi pe “Levi san idamẹwa fun Mẹlkisedeki nigba ti o wa ninu Abraham, baba rẹ”. Abraham bi Isaaki; Isaaki bi Jakobu; Jakobu bi Levi. Eyi ni bàbá, bàbá a bàbá, ati bàbá a, bàbá a, bàbá. Nigba ti Levi si wa ninu baba nla rẹ kẹta, Bibeli fun ni akayẹ yii pe o ti san idamẹwa fun Mẹlkisedeki. Bi aba n sọrọ nipa Ainipẹkun! Ah ah!

34 Ko wi pe “o see ni akawe; o tilẹ see ni ipamọ ni”. Bibeli wi pe “o san idamẹwa”. Amin. Nigba naa, bi awa ba wá nipasẹ Iru ti o tọ́, nigba ti Pọọlu waasu Ihinrere, mo wa nibẹ, iwọ pẹlu wa nibẹ. A oo de inu eleyi laipẹ, titi a o fi ni ẹkunrẹrẹ rẹ. Kiyesi i, ohun ti Iwe Mimọ sọ siwa niyẹn, ani lati atẹyin wa.

Saa ro o! Levi jẹ ọmọ Jakọbu. Jakọbu jẹ ọmọ Isaaki, Isaaki jẹ ọmọ Abrahamu. Baba nla rẹ kẹta. Nigba ti Levi wa ni iha baba nla rẹ kẹta lọhun, o san idamẹwa fun Mẹlkisedeki.

35 Mo fẹ beere lọwọ rẹ. “Tani eleyi n sọ nipa rẹ ni Jobu 38, nigba ti o wi pe ”Nibo ni iwọ wa nigba ti Mọ fi ipilẹ aye sọlẹ? Nigba ti awọn irawọ owuro kọrin papọ, ti awọn ọmọ Ọlọrun kigbe soke fun ayọ?“ Taa ni awọn ọmọ Ọlọrun wọn yẹn ti wọn nkigbe fun ayọ. Jesu sọ fun wọn pe ”Mo ni ayọ pẹlu u Rẹ saaju ipilẹṣẹ aye“. Awa kii se ẹda àkókò. Awa jẹ ẹda Ainipẹkun. Ko si ẹni ti o lee tọ Mi wa, bikose pe Baba Mi ba faa. Gbogbo awọn ti o ba si tọ Mi wa, Emi yoo fun un ni Iye Ainipẹkun. Emi yoo si ji i dide ni opin ọjọ. Ko si ẹni ti o lee ja wọn gba kuro lọwọ Baba Mi, Ẹni ti o fi wọn fun Mi. Bawo lo se lee padanu? Woo, o n foya. O n bẹru. Iwọ n sa kaakiri. Eyi si jẹ ọkan lara awọn ẹri ti o daju julọ ninu aye wi pe, iwọ ko tii de ibi ti o yẹ. Otitọ ni yii.

36 Bawo ni Ọlọrun se lee gba ọ la bi Oun ba …… Ẹni melo ninu ile isin yii, ni yoo na ọwọ rẹ soke ti o gbagbọ pe Ọlọrun ko lopin? Iwọ mọn itumọ ọrọ ti a n pe ni “ailopin”? Iyẹn sa a jẹ pipe. Ailopin. Iwọ ko lee se alaye ọrọ naa, “ailopin”

Njẹ iwọ ti mu ẹrọ ti a fii ya foto, ki o si fi wo ailopin? Họwu! o kan jasi; lati ihinyi lọ títí, títí. O dara. Ko si bi o se le e tun un yi mọ́. O dara, oun ti Ọlọrun jẹ niyẹn. O jẹ Ailopin. Bi O ba si jẹ ailopin, ko lee si kòkòrò tabi esinsin, tabi oun to kere julọ kan, tabi ohunkohun ti o ti wa laye ri, tabi ti yoo wa, bikose pe Ọlọrun ti mọn ọn ki a to da aye. Eyi ni ero diẹ lati se alaye ailopin.

37 O dara naa, Ọlọrun Ailopin ti O gba ọ la loni, ti o si mọn wi pe, Oun yoo padanu rẹ ni ọsẹ ti n bọ, tabi osu ti n bọ, tabi ọdun ti n bọ. Họwu! Oun yo maa ja Ara Rẹ ni tanmọ ọn. Ko lee sọ ọ nu. “Ẹni ti o ba gbọ Ọrọ Mi ti o si gba Ẹni ti o ran mi gbọ, ti ni Iye Ayeraye, oun ki yoo si wa si idajọ, sugbọn o ti rekọja iku si Iye”. Ko lee sọ ọ nu. Iwọ ko lee… Ẹni ti a bi nipa ti Ọlọrun kii dẹṣẹ nitori ti iru Ọlọrun wa ninu rẹ̀, ko si lee dẹṣẹ. Bawo lo se lee dẹṣẹ nigba ti ẹbọ ẹṣẹ kan wa fun un? Bawo ni mo se lee saisan, nigba ti wo wa ninu ilera pipe? Bawo ni mo se lee fọju, nigba ti mo riran? Bawo ni mo se lee wa ni ita gbangba nigba ti mo wa ninu ile nigba kan naa? Ko see se. Nigba ti a ba si gba ọ la, o wa labẹ Etutu nla naa. Ko si ka ẹṣẹ rẹ si ọ lọrun.

38 Dafidi ko ha wi pe, “Olubukun ni fun ọkunrin naa, ẹni ti Ọlọrun ko ka ẹṣẹ si ni ọrun, ti a ko ka ẹṣẹ fun”? Ọlọrun ki i ka ẹṣẹ si “ẹda ti O ti gbala yii” lọrun. Eyii kii se wara rara. Sugbọn Bibeli ni. Ọlọrun ko ni kọ ẹṣẹ silẹ fun Olododo. “Ọlọrun”nipa oore-ọfẹ Rẹ, nipasẹ iyantẹlẹ “ko fẹ ki ẹnikẹni ki o segbe, sugbọn ki gbogbo eniyan lee wa si ironupiwada”. Sugbọn nitori ti Ọlọrun jẹ Ailopin, O si mọn ẹni ti yoo gbagbọ ati ẹni ti ko ni gbagbọ, O lee se iyantẹlẹ ohun gbogbo lati sisẹ pọ fun ifẹ Ẹ Rẹ.

Bi ko ba se bẹẹ, ki lode ti o fi gba ẹsẹ laaye ni ibẹrẹ? Nigba ti o jẹ Olugbala….. Bi ko ba si ẹlẹsẹ, oun ko ba ma lee jẹ Olugbala. Agbara akayẹ, ti o wa ninu Ọlọrun, ko ba ma lee farahan fayeri.

39 Bawo ni o se di Oluwosan? Bawo ni o se di Oluwosan. Nitori pe o gba aisan laaye lati wa, ki Oun ki O lee fi Ara Rẹ han gẹgẹ bi Oluwosan. Oluwosan ni O kọkọ jẹ. Bawo ni a ba se daa mọn ni Oluwosan? Bawo ni agbara Ikayẹ Rẹ iba se lee sisẹ? Bawo ni O se le e jẹ Oluwosan bi ko ba si aisan? O nilati gba aisan laaye.

Ko yanilẹnu; Pọọlu ni Roomu 8 wi pe "iwọ asiwere eniyan, ta ni o lee sọ fun amọkoko ohun ti yoo fi amọ̀n se? Se o seese ki amọn dide ki o wipe," Eese ti iwọ fi mọn mi bayii? Oun ko ha gbe Farao dide fun idi yi kan naa, ki Oun lee e fi ogo Rẹ han ni Egipiti? O n sé ọkàn tí Ó fẹ́ le, O si n dá ẹni tí Ó fẹ́ láre. Kìí se ti ẹni tí n fẹ́, tabi ti ẹni tí n sáré, sugbọn Ọlọrun Ẹni ti n saanu. Nitori naa, iwọ ko ni ohun kan lati se nipa rẹ. Iwọ ko ni ohun kan lati se. Bi o ba jẹ oore-ọfẹ, bi o ba jẹ ebun ọfẹ, ko si ohun kan ti o lee se sii. Ọlọrun ti fii fun ọ, eyi ni si ni ifẹ Ọlọrun. Ohun ti Ọlọrun ti yantẹlẹ fun ọ.

40 Bibeli wi pe, a ti yanwa tẹlẹ si isọdọmọ awọn ọmọ Ọlọrun saaju n ipilẹsẹ aye. Nigba ti Ọlọrun pa Ọdọ-Aguntan naa, ninu ero Rẹ saaju ipilẹsẹ aye, lati fi awọn agbara ikayẹ Rẹ daniloju, ohun ti Oun jẹ tẹlẹ. Nigba ti a pa Ọdọ-Aguntan naa, a pa wa pẹlu Rẹ. Nigba ti a gba ẹjẹ Ọdọ-Aguntan ni ninu ero ọkan Ọlọrun saaju ipilẹsẹ aye, a kọ orukọ mi ati tirẹ sinu Iwe Naa, nigba naa, ninu ero ọkan Nla Rẹ. Ailopin ni. Bi Oun kii ba se bẹẹ ni, kin ni idi ti O fi gbaa laaye?

41 Ewo lo lagbara ju (gẹgẹbi mo ti sọ tẹlẹ), Olugbala tabi ẹlẹsẹ? Ewo ni agbara rẹ pọ ju? Nigba naa eyi ti o lagbara ju ni o ni lati gba eyi ti ko lagbara tó o laaye, Oun si see fun Ogo Rẹ nikan.

Nigba ti o da Lusiferi, O mọn wi pe, yoo jẹ esu. O ni lati jẹ ki o wa nibẹ ki Oun lee fihan pe Oun ni Olugbala, Kristi naa. O ni lati jẹ ki o sẹlẹ bẹẹ. Wayi o, njẹ Bibeli ko ha sọ wi pe, ohun gbogbo ni o nsisẹ pọ fun rere fun awọn to fẹ Ọlọrun (Ipejọpọ wi pe, "Amin") kin ni o n ba ọ lẹru nigba na? Ẹ jẹ ki a maa lakaka pẹlu ọkan fun ijakadi ti o lee de. Mase dabi maluu aláìleè sọ̀rọ̀ ti a ni lati fipa mu sisẹ, a ni lati bẹẹ, ki asi maa rọọ lati se nkan. Si jẹ akín-ín-kanjú. Mo nifẹ Iyẹn. Dide duro.

42 Ewi kekere kan ti o maa n ranmi lọwọ nigba ti mo wa ni kekere lọ bayi pe,

Ọlọ́lá kan araa Romu kan wa

Ni ọjọ awọn Ọba-nla, Ilẹ-Ọba-Roomu

Tí ó gbọ́ tí ẹ̀sọ́ ọ Rẹ́ kan tí ó jẹ́ ojo

Niwaju ilé nlá ọlọ́lá yi wi pe

"ah! abo wa ninu igi kan,

Ko si ẹni ti o lee mi igi yi rara,

Ọlọla yi daa lohun wi pe,

"Rara o. Emi yoo se awari ọna,

Lati se aseyọri.

Se o rii bayii. Otitọ niyii.

43 Bi Bibeli ba kọni pe, Jesu Kristi, ọkan naa ni lana, loni, ati titi lae……. Kii se ohun ti o rọrun nigbati mo jade lọ lati agọ ijọsin yi ni ọjọ yẹn, ti olukuluku nsọ fun mi pe "eyi yoo sẹlẹ, tọhun yoo sẹlẹ. Wọn sọ wi pe "Awọn eniyan yoo ka ọ si agba-were-mẹsin, wọn yoo sọ ọ si ẹwọn. Gbogbo igbimọ awọn onisegun yoo lodi si ọ". Sugbọn Ọlọrun sọ fun mi ki n se e. Bibeli wi pe Ọlọrun wa. Sugbọn nisisiyii, ina isọji n jo ni orilẹ-ede gbogbo ti o wa labẹ ọrun. Eredi rẹ? Doju kọ isẹ naa.

Bawo ni o se n doju kọ isẹ rẹ lójoojúmọ́? Njẹ iwọ n bẹru isẹ ti o ri bi?

Se iwọ lee dojukọ isẹ naa ti o wa niwaju? Tabi iwọ ni ọkàn-èrò ti o ti rẹ ti o si sofo? (Mo korira iru ọkan bẹẹ)

Tabi iwọ dojukọ isẹ ti o wa niwaju taara, tabi ibẹru ngba ọkan-ero rẹ nigba gbogbo? Bi o ba ri bẹ ẹ iwọ dojukọ isẹ ti o kan, nipa riro wi pe, iwọ lee see.

Duro tii. Dajudaju. Pinnu ni ọkan rẹ, gẹgẹ bi Danieli ti sọ. Duro ti Ọlọrun.

44 Nibo ni gbogbo eleyi ti sẹlẹ? Bawo ni o se sẹlẹ? Ki lo mu ki awọn eniyan ri bayi? Kin ni idi ti aye fi setan fun iparun? Arakunrin Branham “Salaye fun mi, ki lo mu ki o ro wipe a nilati pa gbogbo aye yi run?” A ti pa a run ni igba kan ri (abi bẹẹ kọ?) Ni iparun akọkọ, ikun omi aye Noa. Bayi awọn ẹkọ ti o jinlẹ ni a fẹ wọnu rẹ yii. A óò si setán lati ka Ọrọ Ọlọrun.

45 Mo fẹ ki ẹ si Bibeli pẹlu mi si iwe Jẹnẹsisi ori kẹta. Bi iwọ ba fẹ mọn ohunkohun, mo lee fihan ọ ninu iwe Jẹnẹsisi, nibiti ẹgbẹ awo kọọkan, ẹkọ agbelẹrọ eniyan kọọkan ati gbogbo ohun ti a ni loni bẹrẹ ni Jẹnẹsisi. Awọn melo lo mọn wi pe Jẹnẹsisi tumọ si ibẹrẹ?“ Dajudaju. A ri Ijọ Katoliki ni atetekọse. Nimurọdu ni oludasilẹ Babiloni. A rii ni aarin Bibeli, a si rii ni Iwe ti o gbẹyin ninu Bibeli. A rii ti o gbiyanju lati fi obirin se oniwasu, ni ibẹrẹ Bibeli, nipa sisin awọn ere kekere ti a fi igi se. Awọn melo lo ti ka iwe itan, ”Awọn Babiloni meji“ ti Hislop kọ? O dara. Wadii rẹ ninu awọn itan wọnyi. Wọn ni obinrin kan…………… Lẹhin naa, se o ranti? Jakobu pẹlu ji awọn orisa baba a rẹ, ọmọbinrin rẹ si fi wọn pamọ si abẹ ara rẹ, o si mu wọn jade ninu aginju, eyi si díbàjẹ́ àgọ́ naa, lẹyin ọrẹyin.

46 O dara. Jẹ ki a ka bayi ni Jẹnẹsisi.

Ejo saa se aláàrékérekè ju ẹranko igbẹ iyoku lọ ti Oluwa Ọlọrun ti da. O si wi fun obinrin naa pe, ootọ ni Ọlọrun wi pe, Ẹyin ko gbọdọ jẹ gbogbo eso igi ọgba?

Obinrin naa si wi fun ejo pe, Awa a maa jẹ ninu eso igi ọgba.

Sugbọn ninu igi ni, ti o wa laarin ọgba Ọlọrun ti wipe, ẹyin ko gbọdọ jẹ ninu rẹ, bẹẹni ẹyin ko gbọdọ fọwọkan an. Ki ẹyin ki o ma ba a ku.

Ejo naa si wi fun obinrin naa pe, ẹyin ki yoo ku ikukiku kan

Nitori Ọlọrun mọn pe, ni ọjọ ti ẹyin ba jẹ ninu rẹ, nigba naa ni oju yin yoo la, ẹyin yoo si dabi Ọlọrun, ẹ oo mọn rere ati buburu.

47 Wo bi awọn eniyan yii se ri loni, wọn n gbiyanju lati mu kuro ninu Bibeli? “Áh hà há, se ko rọrun ki a da omi le eniyan lori, tabi ki a bu omi wọn eniyan, tabi lọna bayi, lọna miiran?” Rara o. Ọlọrun gbe eto kan kalẹ. Ohun naa ni a si ni lati tẹle, Eleyi.

Nigba ti obinrin naa si rii pe, igi naa dara ni jijẹ ati pe, o si dara fun oju, ati igi ti a i fẹ lati mu ni gbọn, o mu ninu eso rẹ̀, o si jẹ́, o si fi fun ọkọ rẹ pẹlu rẹ, oun si jẹ.

Oju awọn mejeji si la, wọn si mọn pe awọn wa ni ihoho; wọn si gán ewe ọpọtọ pọ, wọn si dá ìbà-ǹ-tẹ́ fun ara wọn.

48 Mo fẹ danu duro fun isẹju kan nihin yi. Wayi o, ohun gbogbo ni o ni lati ni ibẹrẹ. Iwọ ni ibẹrẹ. Bayi awa…….Ibi yii ni mo fẹ gbe gbogbo ọrọ naa kà, eyi ti a ti sọ nipa rẹ fun awọn ipade mejeeji saaju eyi ati titi de ihin yi. Ni owurọ yii, a pada lọ, a si sapejuwe rẹ bi ere ori itage; ninu Bibeli, pe, nigba ti Ọlọrun n da aye, nigbati O n se awọn afẹfẹ, lẹhin naa, awọn afẹfẹ na di kalsiọmu ati pọtasi ati orisirisi nkan miiran. O n da agọ ara a rẹ. O ngbe ile naa kalẹ, gẹgẹ bi ọlọgbọn ọ̀mọ̀lé nla a ni, gẹgẹbi Kọngila tii se n kó gbogbo eroja jọ lati kọ ile nla kan. O n se agọ ara a rẹ, O si ti gbee kalẹ sibẹ. O mọn gẹlẹ ninu ọkan Rẹ ohun gan-an ti O fẹ se. Ọwọ́ yii……… Ọlọrun da ọwọ́ yẹn nigba ti o n da aye. Sugbọn O ti da ẹmi mi ki aye ki o to wa. Sugbọn ọwọ yi ati ara yi ni O da nigba ti O da aye. Nitori ti ara yi jade lati inu erupẹ ilẹ yoo si pada si ilẹ, Ọlọrun da iyẹn. O ti gbe gbogbo rẹ, kalẹ ninu akọsilẹ eto Nla Rẹ̀. Nigba ti o bẹrẹ sii da aye, o da ọkunrin, ọkunrin ko si ri bi o se yẹ ki o ri.

49 A lọ ninu rẹ bi ere itage ni owurọ yii. Baba sọkale wa i wo ọmọ Rẹ ti O da ni aworan ara Rẹ lẹhin naa O se iyawo kan fun un, oluranlọwọ kan.

Ranti wi pe, Adamu ni o sọ gbogbo ẹda aye ni orukọ. Ọlọrun da maluu ati awọn ẹranko miiran. Awọn imọn ijinlẹ, ti n gbiyanju lati ẹgbàata ọdun sẹhin lati se awari alafo ti o wa láàárín eniyan ati ẹranko. Eniyan ati ẹranko kin ara wọn, ni ẹran ara, ẹran eniyan ati ti ẹranko, fẹrẹ ẹ bara mu. Obinrin si jẹ ara ọkunrin, ohun ti a mu jade lara ọkunrin. Ko si obinrin ninu gbogbo ẹda ti Ọlọrun kọkọ da. Ọlọrun ti siwọ isẹ ẹ dida ẹda fun ọpọlọpọ ọdun ki o to wa sẹsẹ mọn ara obinrin lati egungun iha ọkunrin.

50 Adamu ti sọ ohun gbogbo ni orukọ tan, sugbọn oun ko ni ẹnikankan fun ara rẹ. Nitori naa, Ọlọrun se oluranlọwọ kan fun un; O mun egungun iha kan lati ara Adamu, O si di alafo naa pada; O si se oluranlọwọ kan fun un. Ọkunrin, ninu ẹmi rẹ tẹlẹ jẹ akọ ati abo.

Obinrin si jẹ ara ọkunrin. Ni igba ti ọkunrin kan ba fẹ iyawo kan fun ra rẹ, bi o ba si jẹ aya rẹ nitooto, iyawo ti Ọlọrun fifun un, yoo kan dabi ara rẹ gẹlẹ ni.

Idi niyii ti ọpọlọpọ idarudapọ fi wa ninu igbeyawo, o jẹ nitori pe, o jade lọ, o si ri ọmọ binrin ti o lẹwa, pẹlu agọ ara ti o dun-un-wo. Iwọ si nifẹ rẹ. Ni kete ti ó ba bimọ rẹ àkọ́kọ́, awọn ẹyin rẹ a ká, yoo si di arugbo pẹlu ara ihunjọ nigba naa, iwọ yoo fẹ lee jade.

Ẹyin obinrin si ri ọmọkunrin kan ti irun rẹ jọlọ, ti o ti da ororo isebẹ iya rẹ si irun, to si jẹ ki irun naa maa dan yọyọ. Laipẹ irun rẹ yo ja danu. Mo mọn iyẹn nipa iriri. Sugbọn kin ni o sẹlẹ? Kin ni o jẹ? O ti fẹran irun yẹn. O yẹ ki o kọkọ gbadura, nitori pe obinrin jẹ ara a rẹ.

Bi o ba si ti gba obinrin kan mọra. Ti o si gba a mọn aya rẹ, yoo ti se amin kan si araa rẹ. A sọ́ bí eleyi ki o le ye ọ. Obinrin miiran ti o ba gbà mọn aya rẹ, ko lee ba amin naa mu. Ọlọrun yoo si jẹ ọ ni iya fun un, saa ranti iyẹn.

51 Iwọ ti o n mu iyawo ẹlomiiran jade, mo gbọ loni nipa ọmọbinrin kekere kan ni ilu yi, ẹni ẹlẹni kekere kan. Mo mọ ọn. Onítẹ́tẹ́ kan si nra awọn asọ daradara fun un, ati awọn nkan bẹẹ. O fi awọn nkan yii fa a loju mọnra. Ẹranko kan ni yoo se nkan bẹẹ. A ko tilẹ lee ka si eniyan. O mọ pe ajá ko bajẹ to iyẹn, sibẹ ẹ npe iya aja ni asẹwo“ O ni iwa omoluabi ju idaji awọn obinrin Jeffersonville lọ. Ẹ si npe iya ẹlẹdẹ ni oniwa-ibajẹ, sibẹ o ni iwa rere ju ọpọlọpọ awọn obinrin America lọ, otitọ ni yẹn.

Mo mọn pe emi yoo sọ oju abẹ niko; mo si fẹ ki ẹ mọ ọn. Otito si ni yii. Awọn obinrin ode oni ko tilẹ mọn iwa omoluabi kankan. Won a wi pe “ohun ti mo se kò da ẹ̀rí ọkàn mi laamu. O dara, iwọ ko ni ẹri ọkan kankan. Kiyesii. Bẹẹ ni. Nigba ti o mọn ohun to tọ ati ohun to kuna.

52 Kiyesii bayi, nigba ti a da ọkunrin yii, Ọlọrun pín ẹmi rẹ. O si mu ẹya kan lara ọkunrin, ni iha rẹ, o fi se obinrin. Lẹhin naa, o mu ẹmi abo, onitiju ninu ọkunrin, o fi se obinrin. O si se ọkunrin ni akọ, ẹmi ti o gboya. Nigba ti o ba si ri ọkunrin kan ti o kere ti o nkun ara pẹlu ikunra, ati eekanna ika ọwọ, mẹrin ni ẹgbẹ kan, marun ni ẹgbẹ keji; ọkunrin ti o si nfi ikunra mu irun rẹ dan yọyọ, ti o la ẹnu silẹ ni iwaju ati awọn nkan bẹẹbẹẹ; ọkan lara awọn ọmọ to lẹwa yi, iwọ saa ranti arabinrin, ohun kan kuna pẹlu ẹda yẹn, ohun kan kuna. O jẹ kiyesii daa daa.

53 Nigba ti o ba si ri obinrin kan, pẹlu siga ni ẹgbẹ kan ẹnu rẹ pẹlu asọ isẹ ọkunrin lọrun rẹ to n wi pe “mo sọ fun ẹ, awe yii, kin ni gan an. Arakunrin, kiyesi obinrin yẹn daadaa, nkan kan kuna pẹlu rẹ.

Obinrin yẹ ko jẹ obinrin, ki o si wọ asọ bi obinrin. Nigba ti Ọlọrun da ọkunrin, o da ni ọna kan. O si da obinrin ni ọna miiran. Nigba ti Ọlọrun si wọ ọkunrin na lasọ, O wọọ ni asọ lọna kan, o si wọ obinrin lasọ ni ọna miiran. Bibeli si wi pe, ohun irira lo jẹ fun obinrin lati wọ asọ to jẹ ti ọkunrin.

54 Ẹyin obinrin ti ẹ n wọ awọn sokoto buburu wọnyi kini ẹ n pe? Sokoto penpe kin ni orukọ asọ yẹn kii se sokoto penpe eleyi ni ẹsẹ gigun “lẹgini” (pedal pushers, overalls, dungarees).

Mo wo ilẹ, wọn sọ pe, “Eyi wa fun awọn ọmọluwabi obinrin”

Mo dahun wi pe, “Rara o. O n se asise ni. Ọmọluwabi obinrin kii wọ iru awọn asọ bẹẹ obinrin lasan lee wọọ sugbọn obinrin to jẹ omoluabi ko ni wọ”. Otitọ ni. Bibeli wi pe, irira ni o jẹ fun obinrin lati wọ asọ ti o jẹ ti ọkunrin ati fun ọkunrin lati wọ asọ ti o jẹ ti obinrin. Awọn ọkunrin si tunbọ n gba ise obinrin sii lojoojumọ, bẹẹni awọn obinrin tunbọ n gba iwa ati ise ọkunrin sii. Kin ni o de gan-an? A oo rii lẹhin iseju diẹ sii nipasẹ Bibeli. Awọn obinrin ko se bi obinrin gidi mọn. Emi ko sọ nipa ẹyin obinrin kristẹni, mo n sọrọ nipa gbogbo aye. Wọn fẹ huwa bii ọkunrin, wọn fẹ ge irun wọn bi ọkunrin, na ọwọ wọn soke lori irin bẹ yẹn, wọn a kọ “ki Ọlọrun bukun America” pẹlu siga ni ẹgbẹ kan ẹnu wọn.

55 Wọn a sare kọja loju popo, wọn a si jade si ori titi mọ́nsọsẹ̀ taara bẹẹ. A kaa ….. mo fẹ sọ ohun kan fun ọ. Ẹyin obinrin ti n wakọ, ẹ fetisilẹ, Billy Paul ati emi ninu irin-ajo ipolongo iwaaasu yipo orilẹ-ede yii ti o gbẹyin, fun osu mẹfa, a ka iye iwakuwa ti o sẹlẹ. Ninu Ọrundunrun ijamba ọkọ ni oju popo, njẹ o mọn iye ti o tọwọ obinrin awakọ sẹlẹ?

Mọkandinlogun pere ni o ti ọwọ ọkunrin sẹlẹ; igba ati mọkanlelọgọrin ni o ti ọwọ awọn obinrin awakọ sẹlẹ.

Obinrin to n wakọ daradara wa. Sugbọn yoo yi ọwọ́ọkọ̀ sibi kibi. Bi iwọ ba si gbiyanju lati daa lẹbi? Bi o ba lọ jẹ ẹni to lẹwa, bi o se duro yẹn ti o n fi ọwọ gba irun rẹ soke, nigba ti ọlọpa ba sunmọ yin, Kia ọlọpa a ti gbè sii lẹyin, iwọ ọkunrin ni yoo jẹbi. Ah! A ko ni ofin mọn. Wọn fi idi otitọ yi mulẹ ni ijelo, ninu ẹjọ ti owo ori ti mo sẹsẹ bọ ninu rẹ. A ko ni ofin mọn. Bi o ba wa……

56 Ko ya mi lẹnu, ohun lo mu ki awọn asofin agba ni ilu ọmọ ọba binrin (England) ko sọ wi pe, “Ijọba nipa ibo didi dabi ọkọ oju omi to lee sare loju omi lai ni idakọro”. Otitọ niyẹn. Ijọba nipa awọn eniyan fun awọn eniyan ti bajẹ patapata, bẹẹ pẹlu si ni awọn afipa-jọba ati gbogbo iyoku. Gbogbo rẹ ni o ti bajẹ. Ko si ohun

miiran lati se ju ki Ọlọrun pa gbogbo rẹ run, bi o ti sọ wi pe Oun yoo se, ki o si bẹrẹ ni akọtun.

57 Kiyesi bayi bi a se sunmọ bibọ Oluwa to. Bayi, nigba ti obinrin yi….. O da oluranlọwọ kan fun un. Obinrin naa si nilati jẹ oluranlọwọ.

Nigba naa…… Bayi, ko ti si oniwaasu kan ti o gba eyi gbọ. Wọn si n gbiyanju lati se alaye rẹ ni ọna miiran, sugbọn sibẹ wọn ko nitumọ si mi. Wọn n gbiyanju lati sọ wi pe Adamu ati Eefa jẹ apulu. Arakunrin, emi ko si sọ eyi lati sawada, sugbọn mo fẹ sọ pe, bi jijẹ apulu ba jẹ ki awọn obinrin mọn pe wọn wa ni ihoho, ẹ jẹ ki a tun fun wọn ni apulu lẹẹkansi. Ẹ si mọ pẹ otitọ ni eyi.

Ẹ mọ pe, kii se jijẹ apulu lo sẹlẹ si wọn, to jẹki wọn mọn wi pe, awọn wa ni ihoho. Dajudaju, kii se iyẹn. O nii se pẹlu ibasepọ. O ni lati jẹ bẹẹ nitori pe wọn mọn pe awọn wa ni ihoho nigba ti wọn jẹ eso ti wọn ko gbọdọ jẹ yii.

Se kii se igi eleso ni obinrin ni? Se eso iya rẹ kọ ni iwọ ni? Iyẹn ni igi naa ti a palasẹ pe wọn ko gbọdọ jẹ.

58 Bayi ohun nla kan ni eyi bayi. Ohun ti o sunmọ eniyan julọ ti imọ ijinlẹ tii mọn nipa ohun ti ẹda eniyan jẹ ……… Wọn wu awọn egungun atijọ kan jade nilẹ, wọn wu awọn ohun isẹnbaye to ti pẹ ninu ilẹ ati apata, wọn si mu awọn ori, awọn egungun ori, apa, ati awọn egungun miiran, wọn si gbiyanju lati jẹ ki o ri bii eniyan. Wọn si mọn pe ohun to sunmọ eniyan ju ti wọn tii ri ni ìnàkí, oun ni ẹda to sunmọn eniyan julọ, sugbọn sibẹ, ko jẹ nkan naa pẹlu eniyan to ga julọ.

Ẹda to kere julọ ni ọpọlọ, ẹda to ga julọ ni eniyan. Ọlọrun si da ẹda lati eyi ti o kere julọ, O si nda wọn dagba sii titi ti o fi da eyi ti o wa ni aworan ara Rẹ. O muu la awọn ẹyẹ ati awọn ẹranko, O n da eyi ti o ga si titi ti o fi de aworan Ọlọrun. O da eniyan ni aworan naa. Iyẹn ni ipele ẹda to ga julọ. Eyi to kere julọ ni legbe-legbe ti yo di ọpọlọ ati bẹẹbẹẹ lọ.

59 Bayi, alafo to sọnu, ti wọn ko lee ri yẹn. Kiyesi Iwe Mimọ bayii. Ọpọlọpọ yin yoo tako eleyi, sugbọn mo fẹ ki o fi sọkan. Ma si se lodi sii lai se wi pe o gbọ otitọ Ọrọ naa. Fetisilẹ.

Mọ mọn wi pe pupọ yin ni ẹ ti n feti si Dokita Dehaan. Dajudaju mo mọ riri ọtọkulu eniyan bi eleyi, ati gẹgẹbi arakunrin rere ti Ijọ Baptisti. O ni ọgbọn ati ọpọlọ to tayọ ohunkohun ti mo tii mọ ri nitori pe, ọjọgbọn oloye nla nipa ẹsin nii se. O si tun jẹ onimọ ijinlẹ nipa ilera ati bẹẹbẹẹ lọ. Ẹni to jafafa ni, sugbọn, O n sọ bayi pe, “Nigba ti awọn ọmọkunrin Ọlọrun ri awọn ọmọbinrin eniyan, pe wọn lẹwa. O mu igbagbọ rẹ ba ti Josephus mu, o si wi pe, wọn wọ inu ara eniyan lọ, ”wọn si fẹ iyawo fun ara wọn. Awọn òmìrán si wa ni ilẹ Nodu. Wọn si fẹ iyawo, wọn ba wọn gbe pọ, nigbati awọn ọmọkunrin Ọlọrun, awọn Angeli to subu ri awọn ọmọbinrin eniyan, ifẹ ibalopọ si lagbara pupọ, ati pe awọn angẹli to ti subu, bi wọn se kun fun iwa ẹsẹ, wọn wọ inu ara eniyan.

Bi wọn ba se bẹẹ, wọn yoo díbàjẹ́ iwosan nipa agbara Ọlọrun, wọn yo si díbàjẹ́ ohun gbogbo to ku. Bi esu ba lee da nkan, ajẹ pe o ti bá Ọlọrun dọgba. Esu ko lee da ohunkohun. Mo fẹ ki o fi han mi, ibi kan pere ti esu ti da ohun kan. Ko lee da nkankan, o kan maa n díbàjẹ́ ohun ti a ti da ni. Esu kii se ẹlẹda. Olùdíbàjẹ́ ni.

60 O dara naa, kin ni o sẹlẹ gan an? Kiyesii? Ero temi ni yii. Alafo to sọnu yẹn niyii. Bayi, ìnàkí wa. Sugbọn ìnàkí ati eniyan ko le ba ara se pọ ki o di ọmọ. O ko lee mu eniyan ati ẹranko kankan se papọ ki o di ọmọ. Iru wọn ko lee dapọ. Bẹẹ ni, o ko lee gba ẹ̀jẹ̀ ẹranko, ki o fi si ara eniyan.

61 Nigba ti mo wa ni ilẹ awọn alawọ dudu, wọn n fi iya jẹ awọn alawọ dudu naa ni ọna ti ko dara. Ẹnikan sọ fun mi pe, “Ẹranko lasan ni wọn jẹ”

Mo wi pe, “Mo tọrọ gafara o. Eniyan bii tirẹ patapata ni wọn jẹ. O tilẹ lee dara ju ọ lọ paapaa! Jẹ ki n sọ fun ọ, nigba ti o ba ni iru iwa yẹn, o ti n pada sunmọ ẹranko. Mo wi pe, ọkunrin yẹn, bi o ba dudu bi eedu, tabi ki o jẹ alawọ omi ọsan bi ti elegede, tabi ki o ni awọ buluu, O le gba ọ lọwọ iku bi wọn ba gba ejẹ lati ara rẹ si ara tirẹ. Sugbọn ma se dan-an-wo laelae lati gba ẹjẹ ẹranko kankan si ara a rẹ. Daju daju, eniyan ni.

62 Nitori pe awọ eniyan kan jẹ dudu, ti omiiran jẹ awọ omi kòkó, ti omiiran si jẹ alawọ omi ọsan, ti omiiran si jẹ funfun, iyẹn ko ni ohunkohun ise pẹlu rẹ. Bibeli wi pe, “Ọlọrun, lati inu ẹjẹ kan ti da gbogbo eniyan” Otitọ pọ́n-bélé si ni yẹn.

Ibi ti a ngbe, iyatọ ninu awọ wa, ko ni ohunkohun i se pẹlu rẹ. Ọlọrun, nipa ẹjẹ kan da gbogbo orilẹ ede bakan naa. Ara Saina: eniyan alawọ dudu ko le sọ wi pe, “Ọkunrin Saina yẹn, awọ rẹ dabi omi ọsan, emi ko ni ohun Kankan i se pẹlu rẹ” Arakunrin rẹ ni i se. Iwọ alawọ funfun ko lee sọ fun alawọ omi ọsan tabi alawọ dudu, eyikeyi ninu wọn pe “Emi ko ni ohunkan i se pẹlu u rẹ, ”Arakunrin rẹ ni i se. Bẹẹ lo se ri.

63 Kiyesii bayi, ohun to sẹlẹ ni yi. Mo gbagbọ, mo si lee fi idi rẹ mulẹ pẹlu Bibeli pe, ẹranko to-pada-dejo yẹn ni o see. Ẹranko-to-pada-dejo naa ni alafo-to-sọnu yẹn, láàárín ìnàkí ati eniyan. Fetisilẹ, Kiyesi bayii,

ẹranko-to-pada-dejo, kii se ẹda afàyàfà tẹlẹ. O jẹ alarekereke julọ ninu gbogbo ẹranko igbẹ.

Bayii, mo lọ wa awọn iwe atumọ ede loni lati ibi gbogbo, lati wadi ohun ti arekereke tumọ si. O tumọ si “lati jafara, kun fun ọgbọn àlùmọ̀kọ́rọ́yí” Itumọ ti o si dara julọ jẹ ti ọrọ Heberu “Mahah! Itumọ rẹ si ni: ”Nini ìmọ̀ tootọ nipa awọn ilana iye“

64 Bayi ẹjẹ ki a kiyesi eleyi fun isẹju diẹ. O jafafa, o ni ọgbọn alumọkọrọyi, sibẹ a pee ni “ejo” Sugbọn ranti pe oun ni o jafafa julọ ninu ohun gbogbo ti o wa, oun ni o si sunmọ eniyan julọ ninu gbogbo ẹranko aye: O sunmọ eniyan pẹkipẹki, kii se ẹda ti o n fàyàfà. Ẹ̀gún naa lo sọ ọ di afaya-wọ-nilẹ-kiri. Bibeli wi pe, oun ni o lẹwa julọ.

Ẹ̀gún naa papa ko tilẹ gba gbogbo ẹwa rẹ kuro tan. Sibẹ, gbogbo awọn awọ ejo si lẹwa, ati irin ọla rẹ, ati ọgbọn arekereke rẹ. Ẹ̀gún naa gan aa ko gba gbogbo rẹ kuro tan. Sugbọn ranti, Ọlọrun sọ fun un pe, awọn ẹsẹ̀ ẹ rẹ̀ yoo parẹ, yoo si maa fi aya fa kiri. O ko si lee ri egungun kankan ninu ejo ti o farajọ ti eniyan. Idi si niyi ti imọ ijinlẹ fi wáa tì, sugbọn oun ni yii.

65 Ọlọrun ti paámọ́ kuro loju awọn ọlọgbọn ati amoye, o si seleri lati fihan fun awọn ọmọ Ọlọrun. Ni opin aye, nigba ti a oo fi awọn ọmọ Ọlọrun han fayeri. Nigba ti, “awọn ọmọ Ọlọrun yọ̀, ani saaju ipilẹsẹ aye”. Nigba ti ifihan nla nipa 'Ẹniti-Ọlọrun-I-se', ati awọn nkan bẹẹ yoo di mimọn ni igbẹhin aye. Oun yoo fi nkan wọnyi han fayeri nipasẹ awọn ọmọ Ọlọrun. Ẹ mọn wi pe, Iwe Mimọ ni eyi. Awa si ni yii.

Idi niyii ti Ọlọrun fi nsi nkan wọnyi paya fun wa. Ọlọrun n mu awọn Ọmọ Rẹ wa si ifihan-fayeri. Ọlọrun n kọja gbogbo imọ ati oye eniyan, O n kọja si inu awọn isipaya ti Ẹmi, o si n mu wọn sọkalẹ wa.

A ko ha ti ka a ninu Bibeli yii, “Eyi yi ni fun ẹni ti o ni Ọgbọn?” Kii se ohun kan ti o kọ́, ninu ile ẹkọ Bibeli, sugbọn ohun ti o wu Ọlọrun lati fifun un. Awọn ọmọ Ọlọrun ti a fihan faye ri.

66 Eyi ni ẹranko-to-pada-dejo naa, eyi ni ohun ti o jẹ tẹlẹ, mo fẹẹ se apejuwe rẹ fun ọ.

A ti bẹrẹ lati légbélègbé, de ọ̀pọ̀lọ́, siwaju ati siwaju titi ti a oo fi kan ọ̀bọ, titi de ìnàkí. Ati lati ìnàkí, lẹẹkan naa, a ti ìnàkí bọ si eniyan, a si beere wi pe, bawo lo se jẹ? 'O dara,' Imọ ijinlẹ wi pe, “ẹ duro na! a ko lee pa eniyan ati ọbọ papọ mọn ìnàkí, ko lee seese lati mu eniyan ati ẹranko bimọ. Ẹjẹ wọn ko ni papọ. Ẹjẹ tirẹ gẹgẹbi eniyan yatọ patapata si ẹjẹ ẹranko gbogbo. Ẹjẹ kan wa ni alafo yẹn, wọn ko si lee ri ẹranko naa. Ah! Halleluya: Mo kunfun ayọ nisisiyi.

67 Kiyesii. Kin ni? Ọlọrun fi pamọ fun wọn. Ko si egungun kan ninu ejo to farajọ egungun eniyan. Ọlọrun mu ki o jinna réré sii to bẹẹ ti awọn ọlọgbọn aye ko lee wa a ri.

Emi yoo fi han ọ, ibi ti ọlọgbọn aye yẹn ti wa, ati ibi ti o wa. Se o ri i, ko lee wa eleyi ri. O ni lati wa nipa ifihan. “Iwọ ni Kristi naa Ọmọ Ọlọrun. Lori apata yii, Emi yoo kọ Ijọ Mi; ẹnu ọna isa oku ki yoo bori Rẹ”, Ifihan Ẹmi.

Bawo ni Abẹli se mọn lati fi ọdọ-aguntan rubọ, dipo Kaini ti o fi awọn eso igi rubọ. Nipa isipaya Ẹmi ni a fi han fun un. O ko lee rii gba ni ile ẹkọ Bibeli. Oko lee gba nipasẹ Ijọ-ẹlẹkọ-adamọ. Iwọ yoo gba lati Ọrun.

68 Bayi, kiyesi ẹranko-to-pada-dejo nigba naa, ni ibẹrẹ. Jẹ ki a ya aworan-an rẹ. Ẹni to tobi, to si sigbọnlẹ ni. O wa laarin ìnàkí ati eniyan. Esu, Lusiferi si mọn pe ẹjẹ ẹranko-to-pada-dejo nikan ni o lee dapọ mọn ẹjẹ eniyan lati dọmọ, oun nikan ni oun lee lo. Ko lee sisẹ pẹlu ìnàkí, ẹjẹ ìnàkí ko ni sisẹ naa. Ko lee sisẹ pẹlu awọn miiran. Ko lee sisẹ pẹlu agutan. Ko lee sise pẹlu ẹsin, ko lee mu awọn ẹranko to ku lo. Ẹranko to-pada-dejo yii nikan lo lee lo.

Jẹ ki a woo bayi, ki a wo o bi o se ri loju. O jẹ ẹda kan to tobi to si sigbọnle. Omiiran isẹnbaye ni. Nibẹ ni wọn ti ri awọn egungun nla wọnyi, emi yoo si fi eyi han fun ọ ninu Bibeli. Bayi, kiyesii finifini, O dara. Ẹda nla yii. Ẹ jẹ ki a sọ pe, o ga bi ẹsẹ bata mẹwa, awọn ejika to tobi. O ri bi eniyan gẹlẹ.

69 O lee mu ki awọn ẹranko gun ẹranko miiran, ki o si bi awọn ẹranko. Bi awọn ẹranko ti ndapọ, wọn n ga si, titi ti o fi de ipele ti eniyan. Sugbọn, alafo to wa laarin eniyan ati awọn ẹranko iyoku, a ti ge e kuro. Awa melo la mọn pe imọ ijinlẹ ko lee ri alafo to sọnu naa? Gbogbo yin lo mọn iyẹn. Kin ni idi i rẹ? Ẹranko-to-pada-dejo yẹn niyii.

Ẹda giga titobi ni. Esu wa sọkalẹ wa si ibẹ, o wipe, mo lee fun un ni imisi“, Nigba ti o ba n wo obinrin ati ise obinrin, ranti pe, esu ni o misi ọ ( ti obirin naa kii sii se iyawo rẹ.) Kiyesii bayi, esu wa o si bọsi inu ẹranko-to-pada-dejo. O si wa ba Eefa ninu ọgba Edẹni, ti o wa ni ihoho, o si baa sọrọ nipa eso ti o wa laarin. Aarin jasi agbedemeji ati bẹẹbẹẹ lọ, oye ọ; ni apejọpọ onirun-un-ru eniyan. O si wi pe, ”O dun gan an. O dara lati woo“

70 Kin ni o se? O bẹrẹ lati ma ba eefa sere ifẹ, o si baa sepọ gẹgẹbi ọkọ. Obinrin naa si ri I wi pe o dun, nitori naa o lọ sọ fun ọkọ rẹ, sugbọn o ti loyun lati ọwọ esu. O si bi ọmọkunrin rẹ, akọbi, ti orukọ rẹ njẹ Kaini, tii se ọmọ satani.

Bayii, iwọ sọ wi pe, “Ko ri bẹẹ” O dara, a o se awari rẹ bi o ba ri bẹẹ, tabi ko ri bẹẹ “Emi yoo si fi ọta saarin iru rẹ, ati iru ẹranko-to-pada-dejo” Kinla? 'Iru ẹranko-to-pada-dejo!' O ni irú kan, Obirin naa si ni irú kan. Iru Obinrin naa, yoo fọ ori rẹ, iwọ yoo si pá ni gìgísẹ̀ rẹ̀“ Ipalara yi tumọ si 'ki a se Etutu'.

Eyi yi ni irú ẹranko-to-pada-dejo. Si kiyesi, awọn ọkunrin meji yi jade wa.

Bayi, ẹranko-to-pada-dejo yii, bi o se duro nibẹ, ẹda to tobi bi omiiran yii. O wa ni inaduro, O si jẹbi pe o se pansaga pẹlu iyawo Adamu. Nibo ni ẹsẹ pọ si loni? Kin ni o sọ nkan da bi o ti ri loni? Bayi, dajudaju, ohun ti mo nsọ ti ye ọ.

71 Nibẹ ni a si rii. Nigba ti eyi sẹlẹ, Ọlọrun bẹrẹ sii pe Adamu ati Eefa. Ọkunrin na si dahun pe, “Emi wa ni ihoho”. Ọlọrun wi pe, “Ta lo sọ fun ọ pe o wa ni ihoho?”

Nigba naa wọn bẹrẹ sii ti ẹbi si ara wọn bi awọn ologun ti maa nse.

O wipe, “Obinrin ti o fifun mi, Oun lo see. Oun lo fi lọ mi. Se obinrin wi pe ”Ẹranko-to-pada-dejo lo fun mi ni apulu jẹ?“ Hówù! Oniwaasu! ki i se bẹẹ lo se wi.

Obinrin na wi pe “Ẹranko-to-pada-dejo lo tan mi” Njẹ o mọn ohun ti titanjẹ ti Eefa sọ yii tumọn si? O tumọn si, “Lati famọra titi ti o fi sere ifẹ”. O jasi, “o dibajẹ rẹ” Esu ko fun un ni apulu jẹ. “Ẹranko-to-pada-dejo ti dibajẹ ẹ mi”. Nigba naa ni ègún ni de.

72 Ọlọrun wi pe “Nitori pe iwọ feti si Ẹranko-to-pada-dejo dipo ọkọ ọ rẹ, iwọ mu iye kuro laye. Iwọ yoo sọ ibanujẹ rẹ di pupọ ati iloyun rẹ yoo wa fun ọkọ ọ rẹ,” ati bẹẹ bẹẹ lọ. “Nitoriti iwọ fetisi aya a rẹ, dipo Mi, inu ilẹ ni Mo ti mu ọ jade (Ẹda Ọlọrun to ga julọ), iwọ yoo pada di erupẹ. ”Ati iwọ ẹranko-to-pada-dejo, nitori iwọ se eyi, a ge awọn ẹsẹ̀ rẹ kuro. Aya rẹ ni iwọ yoo maa fi wọ́, ni gbogbo ọjọ aye e rẹ. A o si korira a rẹ, Erupẹ ilẹ ni yoo si jẹ onjẹ ẹ rẹ“ Ẹ rii bayi, Alafo to sọnu yẹn niyẹn.

73 Bayi, a ri Kaini. Ẹ jẹ ki a kiyesi awọn iwa ẹda a rẹ. Wo Kaini. Kin ni o jẹ? O jẹ olókòwò to jafafa. O n dako, o jafafa, o gbọn pupọ, o kun fun ẹ̀sìn pupọ. Kiyesi awọn akayẹ ẹ rẹ bayi. Sa a ba mi kalọ fun iseju diẹ si. Kaini niyi. O mọn nipa iwa rere. O fẹran ile isin. O kọ ile Ijọsin fun rara rẹ̀, o si mu ọrẹ wa. O se pẹpẹ ijọsin. Ó kó òdòdó sorii pẹpẹ rẹ. O si wi pe, “Se O rii Oluwa, emi mọn pe a jẹ eso apulu, ohun to fa a niyẹn” Ara awọn iru u rẹ si ni ero kan naa sibẹ. O fihan ibi ti o ti wa.

O ko apulu rẹ wa lati oko, o ko si ori pẹpẹ. O si wi pe, “eyi yoo se etutu”.

Ọlọrun wi pe, “kii se apulu”

Sugbọn, nipa ifihan tẹ̀mí, Abeli mọn wi pe, ẹjẹ ni. Nitorina, O mu ọdọ-aguntan wa, o ge ọrun rẹ titi o fi ku. Ọlọrun si wi pe, “Bẹẹ ni, ohun to fa isubu ni yẹn. Ẹjẹ ni”. Iwọ mọn ẹjẹ ti mo nsọrọ nipa rẹ. O dara Ẹjẹ lo fa isubu“. Kiyesi bayi.

74 Nigba ti Kaini rii wi pe Ọlọrun ti tẹwọ gba 'gbara yilẹ mimọ', arakunrin rẹ ati pe isẹ amin ati isẹ iyanu n sẹlẹ pẹlu rẹ, o se ilara rẹ. O wi pe, “A oo fopin si ohun yii” bayii wo awọn arakunrin rẹ, wo awọn ọmọ rẹ titi di oni. 'Mo jafafa julọ' Nitori naa, inu bii. Nibo ni ibinu ti wa? Se o le sọ pe ibinu……..O pa arakunrin rẹ. Apaniyan ni. Se iwọ lee pe Ọlọrun ni apaniyan?

Adamu si jẹ ọmọ Ọlọrun. Bibeli wipe “Adamu si jẹ ọmọ Ọlọrun” Ìbẹ̀rẹ̀ tí ó mọ́n yẹn. Adamu jẹ ọmọ Ọlọrun. Owu yẹn, ilara, ibinu, gbogbo rẹ ko lee jade lati orisun Mimọ ni. O ni lati wa lati ibomiran. O si wa nipasẹ satani ti i se apaniyan lati ibẹrẹ. Bibeli wi pe o jẹ opurọ ati apaniyan lati ibẹrẹ“ Oun si ni yẹn. O pa arakunrin rẹ

Eyi si jẹ apẹẹrẹ iku Kristi. Lati inu iyẹn, O gbe Sẹẹti dide lati gba ipo rẹ. Iku, isinku ati ajinde Kristi.

75 Si kiyesi, nibi yii ni awọn òmìrán yin ti wa. Kaini si lọ si ilẹ Nodu. Bi baba rẹ ba jẹ ọkunrin omiran giga bawo ni Kaini yoo se ri? Bii baba rẹ. O lọ si ilẹ Nodu, o si fẹ ọkan lara awọn arabinrin rẹ. Ohun kan soso ti o lee se niyẹn. Ko si obinrin miiran ti o lee fẹ bikose, ọmọ Eefa. Itan sọ pe, wọn bi aadọrin ọkunrin ati obinrin. Bi ko ba si obinrin ninu awọn ọmọ Eefa,….. Bibeli kii se akọsilẹ ọmọbinrin nigba ti a ba bi wọn, kiki ọkunrin. Bi ko ba si si obinrin miiran lẹyin Eefa, nigba ti Eefa ku, ẹda eniyan iba ti dopin. Eefa nilati bi awọn ọmọbinrin. Kaini si fẹ ọkan lara awọn arabinrin rẹ.

O lọ si ilẹ Nodu, o si fẹ iyawo rẹ. Nigba ti o si gbe e niyawo nibẹ ni awọn omiran nla yẹn, tii se awọn

ọmọkunrin Ọlọrun ti wọn subu; wọn wa ni pase baba wọn, esu, nipasẹ Kaini. Alafo to sọnu naa niyẹn.

76 Si kiyesi iru ẹranko-to-pada-dejo. Woo bayi. Ranti pe iru ẹranko-to-pada-dejo jẹ onifẹ ẹsin. Kiyesi bi o ti n tẹsiwaju bayi, fun isẹju diẹ. Kin ni o sẹlẹ si wọn. Jẹ ki n ka ohun kan nihin yii ti mo kọ silẹ lọsan yii. Kin ni o ti ila Abẹli jade? Feti si eleyi.

O dara, Abẹli de. Lẹhin Abẹli, ni Sẹẹti de. Lẹhin Sẹẹti, ni Noa, lẹhin Noa ni Sẹmu. Lẹhin Sẹmu ni Abrahamu. Lẹhin Abrahamu Isaaki. Lẹhin Isaaki Jakọbu, lẹhin Jakọbu ni Juda. Lẹhin Juda ni Davidi. Lẹhin Dafidi ni Kristi de si pipe.

77 Kiyesii ni ibẹrẹ bi Ẹmi Ọlọrun se gbe inu Abẹli. Wo bi o se gbe inu Sẹẹti. Wo bi o se gbe inu Juda. Wo bi o se gbe inu Davidi. Wo bi Ẹmi kanna se n pe jade nipasẹ Iru olododo, lati ibẹrẹ lọ titi de opin. Ohunkohun to wu ki wọn se, a yan wọn tẹlẹ.

Wo Jakọbu, oniwa idọtin………. Emi ko sọ nkan yii lati tabuku ohun Mimọ. Sugbọn Jakọbu, atannijẹ, to n so mọn iya rẹ kiri, ọkunrin bi obinrin ni. O se nkan lati tan baba rẹ jẹ, lati gba ibukun naa. Sugbọn a ti fifun un saaju ipilẹsẹ aye. Bẹẹni, a ti fifun. O jade lọ, o si purọ fun baba iyawo rẹ, o mu igi to sami si lara, igi pọpulari, si inu omi lati mu awọn aboyun ẹran, ki wọn lee bi ẹran ọsin to ni amin lara, ki o le yan baba iyawo rẹ jẹ, ki o si gba awọn ẹran ọsin ana rẹ. Ọlọrun bukun un ninu rẹ. Ooto̩ niyẹn. Egbe ni fun ẹnikẹni to ba sọ ohun kan lodi si Jakọbu.

78 Ẹ gbọ ohun ti wolii eke ni wi, sibẹ o sọtẹlẹ ohun tòótọ́. Balamu wi pe, "Ẹnikẹni to ba bukun ọ ni a oo bukun, ati ẹni ti o ba fi ọ ré, ni a oo fi ré"

"Emi mu ọ Jakobu, Emi ri ọ ni ilẹ ajeji. Ati bi ẹyẹ idi ti maa n gbọ,n itẹ ẹ rẹ, Emi gbọn ọn mo si gbe e jade" Halleluya! "Kii se nipa agbara tabi ipa, sugbọn nipa Ẹmi mi, ni Oluwa wi".

Kiyesii bi o se n tẹsiwaju titi fi de Pipe e ni. Ẹmi naa sisẹ titi fi de Pipe ninu Kristi. Ninu gbogbo awọn baba nla, o tẹsiwaju titi. Ohun y'owu ti wọn se, ohun ti wọn sọ, ohun ti wọn se, sibẹ wọn jẹ iru Olododo patapata.

79 Bayi, nigba ti Abrahamu olododo……. Ah! Ogo. Inu mi dun rekọja bayii. Nigba ti Abraham olododo pade Mẹlkisedeki ti ise Ọlọrun funrararẹ. Ta ni Mẹlkisedeki? Ọba alaafia. Ko ni baba, koni iya. Ko ni ibẹrẹ ọjọ, tabi opin ọjọ. Ẹni ti o wu ti iba a jẹ, O wa laaye sibẹ. "A ko bi I rara, ko lee ku rara. Ko ni baba tabi iya ri. Ko ni Ọjọ ti o bẹrẹ tabi opin Rẹ" sọ fun mi Ẹni ti I se. Ọlọrun Ainipẹkun ni. À á à. Mo gbagbe ohun ti ẹ n pe bayii. Tìófánì, Ara Ọrọ. Kii se, arosọ tabi itan lasan. Sibẹ, O jẹ Ẹnikan to farahan fayeri. Bi o se tọ Abrahamu wa ninu Agọ, bii angẹli, ti O si sọtẹlẹ, O sọ fun Sara. Sara si rẹrin lẹhin Rẹ ati bẹẹ bẹẹ lọ. Ohun naa, bakan naa. A si rii nihin, O pade Melkisedeki. Baba nla naa, Abraham ninu Iru olododo san idamẹwa fun Melkisedeki, a si ka a si fun ọmọ, ọmọ, ọmọ rẹ ninu Iru olododo.

80 Wo iru ẹranko-to-pada-dejo. Bayi, ranti, ikorira ati ogun yoo wa laaarin iru mejeeji. Iru ẹranko-to-pada-dejo naa tẹsiwaju. Ki si ni o mu jade? Jẹ ki a wo awọn ọdun wọn akọkọ. Kiyesi ohun to sẹlẹ nibẹ. A oo ka taara jade, tori pe, mo sẹsẹ yẹẹ wo ni.

Iru ẹranko-to-pada-dejo bí Kaini. Kaini lọ si ilẹ Nodu, O bi awọn Òmìrán, wọn si wa si ilẹ Noa. Wọn jafafa, ọ̀mọ̀wé ati ọlọgbọn eniyan niwọn. Se otitọ ni yii? Wọn jẹ kọlekọle, asawari imọ, onimọ ijinlẹ, kii se ninu ila iru olododo, sugbọn nipa iru ti satani, iru ẹranko-to-pada-dejo. Wọn jẹ onimọ-ijinlẹ, onimọ-ẹrọ, awọn ọ̀tọ̀kòlú, ọmọwe. Iwe Mimọ sọ bẹẹ. Wọn fi idẹ se isẹ, wọn fi irin se isẹ, wọn fi awọn ohun alumọọni ilẹ sisẹ. Wọn se awari imọ ẹrọ tuntun. Wọn po orisirisi ohun alumọọni pọ̀, wọn si kọ ile nla-nla abb. Iwe Mimọ sọ bẹẹ. Wọn si jẹ apẹ̀gàn Iru Obinrin naa. Noa olododo. Se otitọ ni? (Apejọpọ sọpe, "Amin")

81 Jẹ ki a tẹle wọn siwaju sii. Lẹhin naa ki a ba wọn de ibi ọkọ Noa, a si pa ohun gbogbo run. Aye de inu gbàrọgùdù ẹ̀sẹ̀, wọn si n se akoso, wọn jafafa, wọn si kun fun ọgbọn aye. Titi ti Ọlọrun fi wo aye, ti ko si ri eniyan pupọ mọ to sẹ ku. Nitori naa, O mu Noa ati ẹbi i rẹ sinu ọkọ naa, O sirọ ojo, O fi pa gbogbo aye run. O si gba Ẹnoku soke saaju ikun omi. Se otitọ ni yii? (Apejopọ wi pe, "Amin"). Iru naa ni yẹn, o fẹrẹ pa gbogbo iru naa, sugbọn, Ọlọrun ni èrò-ùngbà ti a ni lati mu sẹ.

82 Bayi, Noa ati awọn ọmọkunrin rẹ, ti o jade wa, Hamu, Sẹmu ati Jafẹti jade wa ni ila ti Irú Olódodo. Bawo ni iru ẹranko to-pada-dejo se kọja si ẹhin ikun omi? Iru naa kọja ninu ọkọ pẹlu, gẹgẹ bi o ti se ni atetekọse, nipasẹ obinrin, iyawo wọn. Wọn gbe iru u satani, la ọkọ kọja, gẹgẹ bi Eefa ti gbe iru satani, lati bi Kaini, nipasẹ obinrin. Ẹ n fi awọn obinrin si ori pẹpẹ iwaasu yin gẹgẹbi oniwaasu, Bibeli si daa lẹbi! Pọọlu wi pe "Bi ẹnikẹni ba ro wi pe oun jẹ wolii, tabi ẹni ẹmi, jẹ ki o gba wi pe, ohun ti mo kọ jẹ awọn asẹ Oluwa. Sugbọn bi o ba jẹ alaimọkan, ki o jẹ alaimọkan sibẹ"

83 Idi niyẹn ti mo fi jade kuro ninu ijọ Baptisti. Arakunrin Fleeman wa nihin ni ijelo, mo ro pe o wa nibẹ lalẹ

ọjọ naa. Dokita Davis wi pe, “O gbọdọ duro si iwaju lati yan awọn obinrin yii gẹgẹ bi oniwaasu”.

Mo wipe, “Emi ko nii see. Rara ati rara”

O wipe, “O dara, emi yoo le ọ jade”. Mo wipe “Wọn ti le mi jade nibi to san ju eyi lọ. Ọrọ Ọlọrun ni yii, O si da ohun yii lẹbi. Emi ko si lee se ohun ti Ọlọrun da lebi, rara!”. Ẹnikẹni to wu ko jẹ, o fihan pe olukọ eke ni wọn, woli eke ni. Bibeli wi pe, “wọn yoo wa.” Wọn yoo tan ayanfẹ papa jẹ bi o ba seese“ Ẹ ri i bayi.

84 Kiyesii bayi. Lati ibẹ ni Hamu ti jade wa. Hamu pẹlu iyawo rẹ, a fi wọ́n ré. Lati inu Hamu, Nimurodu jade, ti o kọ Babiloni. Lati inu Babiloni ni Ijọ Katoliiki ti jade, ipilẹ rẹ̀ ni. Titi de ori Ahabu. Lati inu Ahabu titi o fi kan Judasi Isikariotu, O de orii rẹ: Asodi-si-Kristi. Ni opin ọjọ yii, eyi ni ẹmi asodi-si-Kristi. Ẹmi asodi-si-Kristi n wi pe, “Awọn ọjọ isẹ iyanu ti kọja”. Ẹmi Kristi n wi pe, “Jesu jẹ ọkan naa lana, loni ati titi lae”.

Ẹmi asodi-si-Kristi n wi pe, “Ko si iyatọ bi a ba tẹ ọ bọmi ni Orukọ Baba, Ọmọ, Ẹmi Mimọ, tabi ka da omi le ọ, tabi bu omi wọn ọ, eyikeyi ti o ba se, ọkan naa ni o jasi”. Bibeli wi pe, Ọlọrun ko lee kuna, ko si lee yi pada. Tani iwọ yoo sin? O ku sọwọ ọ rẹ.

85 Bayi, iwọ wi pe, “se wọn lee gbe papọ?” O sọ pe, “Arakunrin Branham, iwọ ni Hamu ati Sẹẹti papọ ninu ọkọ̀ Noa?” Bẹẹ ni. Otitọ ni. Hamu jẹ ibi, Seti si jẹ olujọsin ati olododo. O dara. Jẹ ki a tọpinpin Hamu.

O dara bayi, Hamu ati Seti wa ninu Ọkọ kan naa, ọkan jẹ olododo ekeji si jẹ alaisododo. Ẹyẹ igun ati adaba wa papọ ninu ọkọ naa. A ri Judasi ati Jesu ninu ijọ kan naa. Eyi ni ni asodi-si-kristi ati Ẹmi Mimọ ninu ijọ kan naa. Loni pẹlu, awọn ẹmi kan naa n sisẹ. 'wọn ni apẹẹrẹ iwa-bi-Ọlọrun wọn si sẹ agbara Rẹ'. Ni apẹẹrẹ iwa-bi-Ọlọrun, wọn si sẹ agbara Rẹ. Ẹ ya kuro lọdọ awọn bẹẹ.

86 “Ẹmi Mimọ n kede, Jesu Kristi, Ọkan lana, loni ati titi lae” Ewo ni iwọ yo o mu?

Asodi-si-kristi n wi pe, “Eyi kan jẹ iwe-ekọ-adamọ lasan”. “A o o ka (Ijẹwọ igbagbọ wa) Ẹkọ-adamọ-awọn-Aposteli.” Mo pe oni-waasu ko-ni-waasu nija pe ko fi ẹkọ-adamọ-awọn-Aposteli (Ijẹwọ Igbagbọ) han mi ninu Bibeli. “Mo gba Ọlọrun Baba, Olodumare gbọ, Ẹlẹda ọrun ohun aye, mo gba Jesu Kristi gbọ, Ọmọ Rẹ kansoso, Oluwa wa. Mo gba Ijọ mimọ Katoliiki gbọ, idapọ awọn eniyan mimọ” Nibo ni ẹ ti ri iyẹn ninu Bibeli? Sibẹ, ẹ n ka a ninu awọn ile isin nla ti Mẹtodisti ati Baptisti. Ẹkọ esu ni wọn. Awọn wolii eke lo si n kọ ọ.

87 Mo si lero pe, emi ko ni mu ọ binu, sugbọn mo n tẹnu mọn iyẹn fun ile isin yii. Ẹyin ti ẹ wa ni Agọ ijọsin ti Branham, ẹ yago fun gbogbo ohun ti o jọ bẹ ẹ. Ohunkohun to ba gbagbọ ninu biba oku sọrọ (idapọ awọn eniyan mimọ tii se awọn ẹni mimọ to ti ku), iboku-sọrọ ni, iba-ẹmi-esu-lo ni. “Alagbawi kan lo wa laarin eniyan ati Ọlọrun, eyii ni si ni Ọkunrin naa Jesu Kristi.” N ko fẹ mọ iye Maria ti o wa!

Se ẹ ri bi iru-obinrin naa ti se nigba yẹn? Se ẹ ri bi iru obinrin naa se kọja ọkọ Noa?

Ẹ wo Amẹrika loni. Amẹrika ni ibujoko esu. Kin ni? O jẹ orilẹ-ede obinrin. Ẹ ti gbọ ti wọn wi pe, “Aye awọn obinrin ni a wa yi”. Ootọ ni, Orilẹ ede obinrin ni. Awọn lo n dari.

88 Mo lọ si ibi kan ni ijelo ni Switzerland. Awọn obinrin nsọ wi pe….. Obinrin kekere to ni Ẹmi Mimọ kan wi pe, “Se o rii, bi mo ba lọ si Amẹrika, wọn sọ pe, awọn obinrin ti gba ominira.”

Mo wi pe, “Jẹ ki n sọ fun ọ, ohun ti ominira yẹn bi jade. ”Mo si bẹrẹ sii sọ fun.´O wi pe, “Ah! Oluwa! Emi ko fẹ ohun to jọ iyẹn”.

Mo wi pe, “ohun ti o yọri si ni yẹn” Se o mọn pe wọn kii se nkan tiwọn, bi wọn ti n see nibi yii. Kin ni?

89 Jẹ ki nfi han ọ pe Amẹrika jẹ Obinrin. Aworan obinrin wa lara owó wa. Ohun gbogbo ni Amẹrika, obinrin ni. Sọ fun mi, ko si bi ile ọtin se lee pọ to ni orile ede yi to lee lagbara to obinrin. Bi ẹ ba ni ogoji ile ọtin mimu ni ilu yii, ti ẹ si fi asẹwo mẹta, ani awọn obinrin to rẹwa ti wọn nlọ kiri loju popo. Awọn obinrin mẹta naa yoo ran ọkàn pupọ lọ si ọrun-apadi nipa ifẹkufẹ, ju gbogbo ile ọtin to lee fi si inu ilu yi lọ. Otitọ patapata ni yii.

Tani nigba naa? Obinrin ni. Kin ni obinrin naa? Orisa Amẹrika ni.

90 Mu diẹ ninu awọn elere ori itage to nse fiimu wọnyi. Wọn ti lọkọ nigba mẹrin tabi marun-un, wọn si ngbe pẹlu ọkunrin mẹta tabi mẹrin nigba kan naa. Awọn iwe iroyin ati-gba-degba si n tu asiri wọn, wọn tilẹ n ya aworan wọn ni ihoho sita-faye-ri. Ẹyin ọmọbinrin si n fi iyẹn se awokọse? Tori kini? Nitori iya rẹ saaju rẹ, tabi iya-iya rẹ saaju rẹ.

Ẹ ri ibi ti iru ẹranko-to-pada-dejo ti n sisẹ loni? Dajudaju, bẹẹni. Kini o si se? Bi a ba bẹ ẹsẹ wo lara awọn ọmọ titi de iran mẹrinla labẹ ofin, iran melo ni a oo fi bẹẹ wo loni? Nigba ti Iru Olododo ti fẹrẹ ẹ pari. Ọlọrun si wi pe, akoko yoo de, bi Oun ko ba ge isẹ naa kuru, ko ni si olododo mọn. A ti de akoko opin aye.

91 Se awari olododo lalẹ yi, la gbogbo inu ilu kọja. Ah! Iwọ yoo ri awọn ọmọ ijọ ti wọn jẹ olootọ si Ijọ Baptisti, Ijọ Pirẹsibiteria, ati bẹẹbẹẹ lọ, bi wọn se lee se to. Sugbọn wọn ko ni ohun kan i se pẹlu Ọlọrun gẹgẹ bi ekute ko se ni ohun kan i se pẹlu bata ti wọn fi n rin ninu yinyin. Wọn ko mo ohun kan nipa Rẹ. Gbogbo ohun ti wọn mọ, "Se kristẹni ni ọ bi?" Wọn a dahun, "Ijọ Katoliiki ni mi"

"Se Kristeni ni ọ"

"Baptisti ni mi"

"Se Kristeni ni ọ?

"Piresibiteria ni mi."

"Se Kristeni ni ọ."

"Pẹntikosita" Gbogbo eyi ko ni ohun kan lati se pẹlu Rẹ̀

O jẹ Kristẹni nitori pe Ọlọrun gba ọ la nipa Oore-ofẹ Rẹ, iwọ si mọn eyii. Ohun kan si ti yi igbe aye rẹ pada, to bẹẹ ti o fi n gbe igbe aye ti o yatọ. O si jẹ eniyan ati ẹda titun ninu Jesu Kristi. Dajudaju.

92 Sugbọn iwọ ri ipo iru eranko-to-pada-dejo? Kin ni iru ẹranko-to-pada-dejo? Pansaga. O ye ọ. Pansaga pẹlu Eefa. Ki lo sẹlẹ si eleyi? Kin ni o mu iyen jade? Ki si ni lalẹ yii?

Wo ẹ̀yìn wò, ni ọdun diẹ sẹyin, nigba ti wọn si ma a nyẹ orin wo ki wọn to gba a laaye ki wọn gbọ lori redio. Eyi akọ́kọ́ to kọja lai si ayẹwo ni eyi, "Ẹ kasọ yin soke, ẹyin ọmọbinrin, ẹ kasọ yin soke, ẹ fi orunkun yin to dunwo han wọn," ati bẹẹbẹẹ lọ "Ẹ fi baba ati mama rẹrin, ẹ fun wọn ni ẹrin kekeke" Iyẹn ni orin akọkọ ninu orin buburu ti wọn kọkọ gba laaye. Nibo ni ẹ ro wi pe ọkunrin ti o kọrin yẹn wa lalẹ yii? O ti ku. Kini o ro nipa Clara Bow, ti o jade wa ti o sọ pe, "Orikerike ara to lewu", ati "ijó to n si ihoho ara han awọn ero iworan" to si ran ẹgbẹlẹgbẹ lọ si ọrun apaadi? Nibo ni o ro wi pe o wa lalẹ yii? O ti pẹ ti o ti ku. Nibo ni o wa pẹlu agọ ara rẹ yẹn. Agọ ara naa ti jẹra ninu erupẹ ilẹ, awọn idin ati ekòló si ti jẹ ẹ tan. Ọkan rẹ si duro niwaju Ọlọrun Onidajọ.

93 Nibo ni ọkunrin naa wa ti o mu obinrin yẹn ti o si rán awọn asọ afihoho han fun awọn obinrin ati asọ to fi gbogbo orikerike wọn han sita? Mo wipe, "Kin ni wọn se eyi fun? Kin ni idi ti wọn fi n wọ iru asọ yẹn? Nitori pe o fẹ ki awọn ọkunrin ma a wo ọ ni, ko si ohun miiran to le jẹ.

Se o si mọn wi pe, nigba ti o ba se iyẹn, ti ẹlẹsẹ kan ba wo ọ, se o mọn ohun to nsẹlẹ? Nibi itẹ Idajọ….. O sọ wi pe, "Arakunrin Branbam, mo jẹ olooto si ọkọ mi bi mo se lee se" Iwọ yoo jẹbi pansaga.

Jesu wipe, "Ẹnikẹni ti o ba wo obinrin lati se ifẹkufẹ sii, o ti se pansaga pẹlu rẹ na, ni ọkan rẹ". Nigba ti ọkunrin yẹn yoo jẹjọ fun pansaga, tani o faa? Bi iwọ se wọ asọ ati bi o se gbe ara rẹ kalẹ ni. Bayi, emi ko sọ pe, o nilati wọ asọ bi ohun to ti pẹ laye kan. Sugbọn iwọ lee ri bi ọmọluabi obinrin.

94 Wọn si jade si oju popo lai wọsọ to bo ihoho wọn, awọn asọ penpe yẹn ti wọn fi okùn tẹ́ẹ́rẹ́ so pọ, pẹlu ọmọ ọwọ rẹ ti oju rẹ dabi ti àwo ti wọn n̩ kan eeru siga si, pẹlu siga ni ẹnu rẹ. O lee má mọọmọ se ohun to buru, sugbọn esu nlo ọ gẹgẹbi irin isẹ rẹ̀ bi o se lo Eefa.

Kin ni idi ti o fi jẹ orilẹ ede obinrin? Nitori pe o n siwaju lati fi ohun gbogbo sabẹ isakoso Ijọ Katoliiki. Kin ni o jẹ loni? O ò kì n gbọ ki wọn darukọ Jesu, "Maria mimọ! Maria Iya Ọlọrun! Cecelia mimọ" Orisirisi awọn ẹni mimọ to ti ku. Ni ijelo ni ibi yii……..

95 Mo wa ni Mexico lọdun to kọja. Obinrin talaka kan wá to n wọ eekun rẹ nilẹ. Orunkun ti o ti fi wọlẹ ti bo. Oun si n sun ẹkun, o n di ọwọ rẹ mu. Baba rẹ si n rin pẹlu rẹ, ti oun ti ọmọ meji to gbe lọwọ, awọn ọmọ yi n sunkun, iya wọn wa ninu irora, nitori pe, obinrin kan ti wọn pe ni ẹni mimọ ti ku. Wọn ni ere rẹ ni ori oke nibẹ, olufẹ rẹ kan ni o paa. Ni kete ti wọn pa a bẹyẹn, o ti di ẹni mimọ ni yẹn. Ọmọ Ijọ Katoliiki ni. Obinrin yi n lọ se ironupiwada, nitori naa, o n wọ lori eekun rẹ fun mẹẹli meji lori okuta lati se isẹ ironupiwada.

Arakunrin, bi ohun kan ba wa ti mo ni lati se fun igbala mi, Jesu Kristi ku lasan. Nipa oore-ọfẹ ni a fi gba mi la kii se nipa ara mi, sugbọn nipa ifẹ ati ojurere Ọlọrun.

96 Lẹhin naa, awọn oniwe iroyin bimi lere pe, "Ọgbẹni Branham …. A ti ji oku ọmọ ọwọ kan dide ati awọn isẹ iyanu miiran. Ọ̀kẹ́ kan abọ ọmọ Ijọ Katoliiki…… Rara, mo tọrọ gafara, Ọ̀kẹ́ kan eniyan ni. Afirika ni ọkẹ kan abọ eniyan ti gbagbọ lẹẹkan soso. Ọ̀kẹ́ kan ọmọ Ijọ Katoliiki gba Kristi gẹgẹbi Olugbala wọn, lẹẹkan soso. Nigba ti iyẹn sẹlẹ, mo duro ni Ilu-nla Mexico. Awọn alufaa yẹn, wọn ko lee sọ ohunkohun. Awọn to gbagbọ ti pọju. O tilẹ lee fa rukerudo igboro. Awọn to faramọ Ọrọ Ọlọrun tipọ ju. Nitori naa, o wipe, "Ọgbẹni Branham, se o gbagbọ pe awọn ẹni mimọ tiwa lee se nkan naa ti iwọ se."

Niwọn igba ti mo mọ ẹkọ wọn, mo wi pe “Dajudaju bi wọn ba wa laaye”. Se o ri ? Iwọ ko lee di ẹni mimọ ninu ijọ Katoliiki ayafi bi o ba ku.

Nitori naa, O dahun wi pe, “Ah! Iwọ ko lee di ẹni mimọ ayafi lẹhin ti o ba ku”.

Mo wi pe, “Nibo ni o ti ka iyẹn?” Pọọlu wi pe, “Si awọn eniyan mimọ ni Efesu ati awọn ti Ọlọrun ti pe”. Si awọn eniyan mimọ ti o wa ni Efesu. O n kọ iwe rẹ si awọn eniyan mimọ ti o wa kaakari ati Galatia, awọn eniyan mimọ ni Romu, ati bẹẹbẹẹ lọ. Awọn ẹni mimọ, awọn ti a sọ di mimọ! Iyẹn nkọ?“

97 O wi pe, “Awa ko gbọdọ jiyan Bibeli nitori pe, awa ni ijọ, ohun ti ijọ ba si ti sọ ni. Awa ko bikita ohun ti Bibeli sọ, ohun ti ijọ sọ ni”. O wi pe, “kin ni ero rẹ nipa ijọ Katoliiki?”.

Mo wipe, “Iba wu mi ki o ma beere iyẹn lọwọ mi, Nitori pe o beere, emi yoo si sọ otitọ fun ọ.

O wi pe, “O dara, mo fẹ ki o sọ otitọ fun mi”.

Mo wi pe, “Ipele ibokusọrọ to ga julọ ti mo tii ri ri.

O wi pe “Bawo lo se lee sọ bẹ yẹn?

Mo wi pe “Ohunkohun to ba n se agbawi pẹlu oku, o jẹ abokusọrọ”.

Mo wi pe, “bi ẹni mimọ yẹn ba sọrọ pada, a je wi pe ọrun-apadi lo wa. Nitori pe, awọn to ti kọja si Ọrun, Bibeli mi wi pe, ko lee pada wa mọn”. Otitọ ni yẹn. Mo si wi pe, “Bi o ba ri bẹẹ, bi o ba jẹ ẹni mimọ nitootọ esu lo nsọrọ bi ẹni mimọ kan, kii sii se ẹni mimọ naa.

O si wi pe, “O dara, duro na, iwọ naa n sipẹ pẹlu oku”.

Mo wi pe, “Nibo”.

O wi pe, “Jesu Kristi ku”

Mo wi pe, “sugbọn O tun jinde lẹẹkansi. Kii se oku mọn. Sugbọn O wa laaye lati se isipẹ fun wa, Oun si ni Alagbawi kan soso, to wa laarin Ọlọrun ati eniyan.

“Emi ni Ẹni naa ti o ti ku, ti O si tun wa laaye lẹẹkansi, Mo si wa laaye titi lae. Mo ni kọkọrọ iku ati ti ipo oku, ẹnikẹni ti o ba fẹ, jẹ ki o wa, ki o si mu ninu omi iye lọfẹ”.

98 Ọlọrun wa niyẹn Ọlọrun wa niyẹn. Iru Olododo si ti fẹrẹẹ tan. Ba awọn eniyan sọrọ nipa nkan wọnyii. Sọ fun wọn pe ki wọn pada si ọna Bibeli. Sọ fun wọn nipa isẹ iyanu. Sọ fun wọn nipa iyẹn. “Ijọ wọn ko gba a gbọ”, Nitori naa, ọmọ-àlè ni wọn si Ọlọrun. Bibeli wi pe, bi iwọ ko ba lee farada inunibini, idanwo, ifi se yẹyẹ, ki wọn pe wa ni “gbarayilẹ mimọ, ati bẹẹbẹẹ lọ, bi o ko ba lee farada a, a jẹ wi pe ọmọ-àlè ni ọ, o kii si se ọmọ Ọlọrun. Bibeli sọ bẹẹ.

Pe mi ni gbarayilẹ mimọ biwọ ba fẹ. Pe mi ni ohunkohun too ba fẹ. Niwọn igba ti ọkan mi tọ pẹlu Ọlọrun, ti iriri mi si ba bibeli Ọlọrun mu, mo n rin lọ taara ni ọna yii kan naa.

99 Ohun ti a gbagbọ niyẹn. Eyi ni Ijọ Ọlọrun Alaaye ti kii wa nipa ẹkọ ẹsin, kii wa nipa àgbélẹ̀rọ ọgbọn eniyan. O n wa patapata nipa isipaya otitọ pe, Jesu Kristi ni Ọmọ Ọlọrun.

Bi o ba jẹ pe mo kan ni erongba ọgbọn eniyan nitoripe ijọ Baptisti tabi ijọ Metodisti ti kọ mi ni ọna kan. Nigba ti mo ba gbọ Bibeli yii, bi o ba se pe, mo ti se itẹbọmi ni orukọ Baba, Ọmọ ati Ẹmi mimọ, ti mo wa ka ninu Bibeli tabi ti oniwaasu kan sọ fun mi pe, ko si ẹni ti a se itẹbọmi fun ninu Bibeli bikose ni Orukọ Jesu Kristi, ti mo si kaa, ti mo rii pe, otitọ ni. Emi yo sa lọ si odo lati tun itẹbọmi se kiakia. Bẹẹ ni.

100 Bi ẹnikan ba sọ fun mi pe, Jesu Kristi jẹ oluwosan nla, ti ijọ mi si sọ fun mi pe, Ọjọ isẹ iyanu ti dopin, ti mo si nilo iwosan, emi yoo sare bi mo ba se lee sare to lọ pẹpẹ yẹn lati gba iwosan. Dajudaju, emi yoo se.

Bi mo ba jẹ oniwaasu, ti mo si ni obinrin oniwaasu kan ninu ile isin mi, ti mo wa ka ninu Bibeli ti mo rii pe obinrin ko yẹ lati jẹ oniwaasu, Emi yo mu un kuro ni ipo naa kiakia, bi eyi ba ma a bo mi lara lati se bẹẹ.

Mo ranti obinrin kan ti o joko nibiti Arabinrin Wright joko si yii lalẹ ọjọ kan, ti o si fẹ ju mi sita lati ẹnu ọna fun ohun kan bi iyẹn. Bẹẹ ni. Mo wipe, “Iwọ ko lee wọ ile isin mi pẹlu asọ ti ko dara.” Nigba ti wọn maa n wọ asọ ti wọn la lọ si ilẹ ti o si fẹrẹ fi ilaji ihoho ara wọn han. Mo wipe, “Bi ẹnikeni ba wa si ile isin mi pẹlu iru asọ yẹn, emi yoo lee jade. Obinrin yi wa pẹlu asọkasọ bẹẹ. Ko si pẹ lẹhin naa ti o fi ku, o si n kigbe pe mi, bi o ti nku lọ. Ọmọbinrin Ijọ Katoliiki ni. O rin wọle o si joko pẹlu asọ ibajẹ yẹn. Mo wo ọdọ rẹ mo si rii, O joko nibẹ wọn si n kọrin. Mo bọ kootu mi, mo lọ si ọdọ rẹ, mo si fi boo ni ejika yika. Mo wipe, ”Mama, bi o ba fẹ feti si

iwaasu mi, jọwọ fi kootu yii bo ara nigba ti o wa ninu ijọ Ọlọrun. Ẹ rii? Dajudaju.

101 Obinrin naa fi ibinu jade sita, o fẹ awọn ètè yẹn soke. O jade kuro nile isin. O wipe “Bí ó bá rò wi pe òun ni ẹ̀sìn, emi ko lee jẹ ki maluu mi ni iru ẹsin yẹn”.

Mo wi pe ma daamu. Kò ní níi.

Nigba naa, àgọ́ ni a n lo. Wọn n pe mi nigba to n ku lọ. O ni aisan ọkan, o si nku lọ. Ọkọ rẹ wa, o si n pe mi wi pe, “Tete ma a bọ” Mo si wa ninu isin. Ọmọkunrin ti o tobi, to singbọnlẹ, o duro lẹnu ọna, o n duro de mi. Mo si sare……… Mo bọ sinu ọkọ mi, mo si sare lọ sibẹ. Bi mo se gun atẹgun, mo pade agbalagba nọọsi yẹn, to n gbe ni Howard park, titi di isisiyi. O wi pe, “Ẹni ọwọ, ko nilo mọn lati wa” Iyẹn jẹ bii ogun ọdun sẹyin, tabi ju bẹẹ lọ. O wi pe, “O ti ku, O ti di isẹju mẹta to ti ku. O pariwo kikankikan bi o ti leese to, fun ọ. O wi pe, ”Mo ni isẹ kan lati jẹ fun ọ“

Mo wi pe, kin ni?.

O wi pe, “sọ fun oniwasu yẹn, ti mo sọrọ lodi si, sọ fun un 'jọwọ dariji mi'”

102 Mo lọ sibẹ lọ wo o. Arẹwa obinrin. O si ti jiya gan an. Ohun kan ti lé kekeke si imu rẹ, obinrin to rẹwa. Awọn nkan to so si ni oju, han ketekete. Awọn ọmọloju rẹ si ti jade sita patapata, o si yi pada de ilaji. Nitori, awọn ọlẹ̀ ati kíndìnrín inu rẹ ti yẹ kuro ni ipò wọn, ooru si n jade lati gbogbo ibusun naa. Ọkọ rẹ wo mi, o wipe, “Arakunrin Branham, se adura kan fun un, nitoripe, o fẹ ri ọ.

Mo wipe, “sise adura fun un ko ni se e ni ire kankan bayii”. Ibi ti igi ba tẹ si, ni o maa n wo si. Se o rii? Ma se jẹ ki wọn tan ọ jẹ, a ko lee gan Ọlọrun, ohunkohun ti eniyan ba gbin ni yoo ka.

103 Se o ri ibi ti o wa? Bayi ki lo ti sẹlẹ? Wo obinrin kan ti o se iyẹn. Wo awọn obinrin to ti wa tẹlẹ, ọmọbinrin alajota, kin ni ọmọ rẹ tẹlẹ? Omobinrin to njo taka nsufe ni. Kin ni ọmọ tirẹ yoo jẹ? Ha! Kin ni?

Se o ri Iru olododo? Wo iwọ Baptisti. Ronu wo ẹyin wo na. Ranti John Smith, Oludasilẹ yin. Nigba ti o gbadura fun aisedede awọn eniyan, tititi, o kee o si gbadura fun awọn eniyan titi ti oju rẹ fi wu, ti iyawo rẹ ni lati fi onjẹ nuu ni ibi tabili onjẹ owuro rẹ.

104 Ati ẹyin Mẹtọdisti, ti ẹ n fi ohun ọsọ si imu, ati eti, ti ẹ si dabi oun kan ti esu gbe kalẹ, ẹ si n jade pẹlu asọ penpe ati awọn nkan bẹẹ. Nigba ti John Smith, arugbo ni, ọkan ninu awọn alagba Ijọ Mẹtọdisti, ki o to ku ni ẹni ọdun marun-din-laadọrun(85), o waasu tó pè ní kúkúrú fun wakati mẹrin. Wọn ni lati gbee joko sibi aga iwaasu. Eyi si ni ọrọ ti o sọ gbẹyin. O wi pe, “Ẹnu ya mi fun ìse Ijọ Mẹtodisti, awọn ọmọbinrin Ijọ Mẹtọdisti paapaa ti n wọ oruka wura si ika ọwọ wọn” Kin ni yoo sọ bayii, pẹlu asọ penpe ti wọn nwọ ti wọn si fi n kọrin ninu ẹgbẹ akọrin? Ẹ ti se daradara tẹlẹ. Kin ni o wa sẹlẹ? Ẹ n se bi iya yin ti se. Ohun to sẹlẹ ni yẹn.

Idi ni yẹn ti a ko fi fẹ, ikankan ninu awọn ijọ-ẹlẹkọ adamọ wọnyi pẹlu wa. “Awa jẹ Mẹtọdisti. Awa jẹ Baptisti” Awa jẹ kiki ti Kristi. Fi silẹ bayii, wa lominira.

105 Se o ri iru ẹranko-to-pada-dejo bayii? Kin ni obinrin bi eleyi yoo se? Kin ni iyẹn yoo se? Kin ni? Wọn n tẹsiwaju bẹẹ, wọn ti awọn Baptisti sẹyin, wọn ti Mẹtọdisti sẹyin, wọn ti awọn Piresibiteria sẹyin. Kin-in wọn se? Gbogbo wọn lo pada sẹyin, gẹgẹ bi iya wọn agbere atijọ ni ti sẹ. Nibẹ ni gbogbo wọn wa ti wọn n se agbere kan naa. “Odara, ko se pataki rara. A ti tẹ wọn bọ mi. A ti fi omi wọn wọn. Wọn ti wa, wọn ti se ijẹwọ ẹsẹ” Wọn ti se ifasẹhin-kuro-ninu-ọtin-lile fun osu mẹfa. Wọn ko mu ọtin lile pupọ ni akoko naa, abb. Wọn jẹ ọmọ ijọ ti o dara, wọn maa n san owo ọrẹ daradara abb“

Ah ah! Awọn nkan yii ko nii se pẹlu eso Ẹmi. Awọn Eso Ẹmi ni “igbagbọ”, gbigba Jesu Kristi gbọ, ọkan naa lana, loni, ati titi lae: Ifẹ fun awọn ara “ayọ, alaafia, ipamọra, isoore, suuru, iwatutu, ikora-ẹni-ni-ijanu” Awọn nkan yii ni awọn eso ti Ẹmi.

106 Bi a ba mu ọkunrin kan, “O dara, o ngbe igbe aye rere ni adugbo rẹ, Esau se bẹẹ gẹlẹ. Esau ko pa ẹni kankan lara, Esau si jẹ ti esu. Sugbọn Jakọbu, lati inu ikun ọmọ kan naa jẹ ti Ọlọrun. Iru esu naa, Iru obinrin naa, nipase eyi ti Iru Ọlọrun ti jade.

Ẹ rii bayii, ohun gbogbo ti wa de ohun yii, ohun ti o ku ninu aye loni. Emi yoo sọ eleyi lọna lile gidi lati mu ki o ye ni yekeyeke, lẹyin naa a oo bẹrẹ isọji naa ni ipade isin ti o kan. O ti wa de ipo kan bayii. Ẹ jọwọ, emi ko sọ eleyi lati se alai bu ọla fun ohun Mimọ. Emi ko sọọ lati buru. O ti de ipo kan ti gbogbo rẹ ti di kikida ẹgbẹ ẹlẹsin to jẹ awọn ọmọ- àlè. Eyi ni koko ọrọ mi ni ipari.

107 Ohun ti gbogbo rẹ ti da ni yii. O mọn pe didara-pọ-mọ-ijọ ati jijẹ ọmọ ijọ ni o ku, wọn ni afarawe iwa-bi-Ọlọrun, wọn si sẹ agbara Rẹ titi ti o fi ku kikida awọn ọmọ-ale ẹgbẹ-ẹlẹsin lasan. Ohun ti o jẹ niyii gẹlẹ.

Kin-ni o ku? Ado oloro pupọ, ti kobati ti duro abb. Wọn kan nduro de wakati naa lati de. Iparun patapata yoo si sẹlẹ pẹlu ina gẹgẹ bi o ti sẹlẹ pẹlu omi.

108 Ẹyin ọrẹ, ohun yí ó-wù tí ò báàse, bi o ba jẹ kristẹni, ti o si ni Ọlọrun ni ọkan rẹ, ti o si mọn pe o ti rekọja iku bọ si iye, iwọ lo yẹ ki inu rẹ dun julọ ni aye.

Nigba ti Ẹmi Mimọ ni inu rẹ…. Nigba ti Bibeli wipe, "Jesu Kristi, ọkan naa lana, loni ati titi lae" awọn ijọ-ẹlẹkọ-adamọ wi pe "sugbọn awa gbagbọ pe, isẹ iyanu ko si mọn".

Ẹmi mimọ yoo wipe, "Amin Jesu Kristi jẹ Ọkan loni ati titi lae. Bẹẹ ni ki o ri."

109 Bi Bibeli ba sọ wi pe, ronupiwada ki a si se itẹbọmi fun olukuluku yin ni Orukọ Jesu Kristi fun imukuro ẹsẹ yin, ẹyin yoo si gba Ẹmi Mimọ. Nitori ileri naa wa fun yin, ati awọn ọmọ yin, fun awọn alaikọla, awọn ti o wa lọna jinjin rere, iye awọn ti Oluwa Ọlọrun wa yoo pe. "Iye awọn ti Oluwa Ọlọrun wa yoo pe, se o rii, ki i se iye awọn ti Ijọ Mẹtọdisti yoo pe, Baptisti yoo pe, sugbọn iye awọn ti Oluwa Ọlọrun wa yoo pe, yio gba Ẹmi Mimọ yii. A oo si tẹ wọn bọmi ni Orukọ Jesu Kristi, bi Bibeli ti wi.

Nigba ti eyi ba wọ ọkan rẹ, iwọ yoo sọ wi pe, "Aamin"

Ijọ wi pe, "Ah, eyi ko se Pataki"

Sugbọn Ẹmi Mimọ ninu rẹ yio sọ wi pe, Aamin si Ọrọ Rẹ.

"Eniyan ki yoo wa laaye nipa akara nikan, sugbọn gbogbo Ọrọ ti o ti ẹnu Ọlọrun jade". O rii bayii.

110 Mo fẹ ki o fihan mi nibi ti Iwe Mimọ ti figba kan sọ wi pe, apulu lo bẹrẹ ohun ti o n sẹlẹ bayii. Mo fẹ ki o fihan mi pe wọn jẹ apulu. Mo ti fi han ọ ibiti Kaini ti ni ero kan na, ati bi iru rẹ se ni ero kannaa sibẹ. Sugbọn ifihan nipa Ẹmi Ọlọrun fidi rẹ mulẹ nipa Bibeli, pe, ibalopọ laarin ọkunrin ati obinrin ti ko bofin mu lo sẹlẹ. Ibi ti awọn omiran yin ti jade ni yii. Ibi ti ẹsẹ yin ti jade niyii. Ibi ti idibajẹ yin ti wa ni yii. Ibẹ lo ti wa.

Kiyesi gbogbo eleyi, ẹranko-to-pada-dejo jafafa nilọpo meji. Iru rẹ maa n jafafa nilọpo meji ni gbogbo igba. O tilẹ wumi, ki n naduro lori aga iwaasu yii, ki n si gbe gboun gboun si ẹnu, ki n na ẹsẹ̀ mi siwaju lati sọ ọrọ yii. Loni, nibo ni awọn ọ̀mọ̀nwé nlá a yín wà? Olusọ-agutan yin ti o lọ kawe, ti o si ni imọ pupọ, Oun si ni Olusọ-aguntan awọn ijọ ti otobi ju ni orilẹ-ede, abb. Nibo ri iru ẹranko-to-pada-dejo wa? Laarin awọn ọ̀mọ̀wé to jafafa julọ ni. Nibẹ ni o wa. Nibẹ lo duro si. Kii se nipa agbara, kii se nipa ipa, sugbọn nipa Ẹmi Mi, ni Oluwa wi. Sẹ ẹ rii? Nibẹ ni iwọ….

111 Ki a wa wo arakunrin kekere kan ti o duro ni kọrọ ibi kan, to si n ke tantan, boya ti o duro fi gita kan kọrin, to n sọ wi pe, "Arakunrin wa gba Oluwa gbọ.

Olusọ-aguntan ọmọwe yii kọja nibẹ o si wi pe, "A! Emi ko lee jẹ ki apejọpọ mi ati awọn ojugba mi, ri mi ni ibi yi. N ko lee jẹ ki Liddy ati Johnny ati awọn toku rimi ni iru agbegbe yii.

Tẹsiwaju, iru esu, o n lọ si opin aye rẹ lọnakọna. Otitọ ni. Mo fẹrẹẹ lo ọrọ miiran nibẹ yẹn. Kin n sọ pe "awọn ọmọ-àlè" Bo si se jẹ gan na ni yẹn. "Ko si ẹnikẹni ti o lee wa si ọdọ mi, lai sepe Baba Mi faa. Gbogbo awọn ti o ba si tọ Mi wa, Emi yoo jii dide ni ọjọ ikẹhin. Kosi oun kan ti yoo sọ nu. Awọn ti Mo gba la. Emi yoo paamọ. Ko si ohun kan ti o lee se ayafi Eyi. Inu Kristi ni gbogbo rẹ wa. Iwọ ko lee wipe, "Emi ni mo se ohun kan". Ore-ọfẹ Ọlọrun lo se gbogbo rẹ. Nitori naa, ko si ohun kan ti mo se. Emi ko ni ohun kan ise, bẹẹ ni iwọ pẹlu. Iwọ ko ni ẹto si ohun kan nipa agbara rẹ. Ọlọrun lo se gbogbo rẹ, iwọ ko se ohun kan nipa ipa rẹ.

Iwọ ko wi pe "O dara, mo ti ile rere kan wa, mo se bayi" iyẹn ko ni ohun kan i se pẹlu rẹ, Ọlọrun ni o se gbogbo rẹ, aanu Ọlọrun ni.

112 Mo tọrọ aforiji bayi, agogo mọkanla ko tiilu tan, sugbọn emi yoo pari lọnakọna. Ẹrii? Awọn melo lo loye pe Ọlọrun sọrọ nipa nkan wọnyi ati pe otitọ ni? Paapaa julọ ẹyin ile ijọsin Branham Tabernacle. Bayi, ohun ti a waasu yi dabi ida kan ninu ida mẹrin-din-logun ninu ohun ti a nkọni, ti a si gbagbọ. Sugbọn ranti, fun ẹyin ti ẹ kii se ọmọ ijọ yi. Bi awa se gba eyi gbọ pe, Bibeli ni. Bibeli si ni otitọ Ọlọrun.

A si gbagbọ pe ninu Majẹmu laelae, wọn ni ọna kan ti wọn fi maa n mọn, ohun ti o jẹ otitọ ati ohun ti kiise otitọ. Bayi gbogbo wa la mọn pe, wọn ni ofin ti a kọ silẹ. Ẹni melo lo mọn iyẹn. Awọn ofin naa wa ninu Apoti Ẹri, abb. Ati ofin pẹlu awọn asẹ Ọlọrun. Wipe, "Iwọ ko gbọdọ se pansaga. Ẹnikẹni to ba se pansaga, wọn ni lati sọ ọ ni okuta pa. Ofin ni yẹn ati idajọ lori ofin naa. Bayi Apoti Ẹri duro bayi, awọn ofin ti asẹ naa wa ninu awọn apo ti o wa lẹgbẹ apoti naa. Bi ẹnikan ba ti se pansaga, wọn wo inu apo yẹn, lati ri ohun ti ofin sọ, "Sọ ọ ni okuta pa. Wọn a mu un jade, wọn a si sọ ọ ni okuta. Ohun ti ofin sọ nipa asẹ naa ni yii.

113 Wọn ni ọna meji miiran lati mọn. Mẹta ni o maa n wa nigba gbogbo fun ifẹsẹ-mulẹ otitọ. Wọn ni ọna

miiran lati mọn, eyii ni nipa woli kan tabi alala. Awọn melo lo mọn eleyi? Bi ẹnikan ba wa laarin yin ti o ni Ẹmi Ọlọrun, tabi Wolii, Emi Oluwa yoo fi Ara Mi han fun nipasẹ ala, Emi yoo si baa sọrọ nipa iran. Otitọ ni yii. Bayi, onisọtẹlẹ ni.

Bayi, bi ẹnikan ba dide, ti o wi pe, “Halleluya, mo ti rii gba. Emi n sọtẹlẹ bayii ni Orukọ Oluwa. Mo ni isipaya kan.” Wọn kii gba ohun naa ko kan lọ bẹẹ, bi ẹyin eniyan yi se n se. Wọn yoo yẹẹ wo nipa Ọlọrun. Saaju.

114 Bayi, ni igba-aya Aaroni, wọn n pe ohun kan ni 'Urimu Tumimu'. Melo ninu yin lo ti gbọ ọrọ yi ri? Kin-ni? O jẹ okuta mejila, mẹfa lẹgbẹ kọọkan ti awọn baba nla mejila. Jasperi, Judah abb. Okuta mejila. Wọn yoo mu wolii naa, tabi alala naa lọ si ibi ti wọn gbe apata aya Aaroni kọ si, yoo duro niwaju aso naa, wọn a wipe, “sọ isọtẹlẹ rẹ tabi ala a rẹ”

Yoo wipe, “Oluwa sọ fun mi bayi, abb.” Bi o ti wu ki o dabi arigbamu to, o lee dabi pe, otitọ pipe ni, sugbọn bi awọn ina yẹn ko ba a wa papọ bi osumare, ki agbara nla ti Ọlọrun ki o tan imọle naa si ori awọn okuta naa, lati fẹsẹ rẹ mulẹ. Nigba gbogbo ni Ọlọrun ti maa n fi Ọrọ rẹ daniloju pe Otitọ ni. Bi awọn imọlẹ nipa agbara nla Ọlọrun yẹn ko baa wa si oju awọn okuta naa, nigba naa emi ko fẹ mọn bi o se lee jọ otitọ to, o kuna.

115 Bi alaala kan ba wi pe, mo la ala kan, ala yi si wi pe “ki Israeli gbera, ki o si lọ si ibi kan pato, nitori pe awọn ara Siria nbọwa si ibi yii lati gbogun ti yin”. Wọn yoo mu alaala naa lọ siwaju Urimu Tumimu ki o tun ala rẹ sọ niwaju rẹ. Bi awọn ara Siria tilẹ ti pejọ sibi ti o sọ yi. Sibẹ, bi imọle naa ko ba tan ni idahun, a jẹ wi pe, ala naa kii se otitọ, ohun to wu kii ba sẹlẹ, a nilati fi idi otitọ mulẹ nipa Urimu Tumimu.

Gbogbo eniyan lo mọn wipe, Ilana Alufaa ti akoko naa ti yipada, a ti paá tì ati Urimu Tuminu pẹlu rẹ. Gbogbo wa lo mọn eyi, abi bẹẹ kọ,? (Apejọpọ dahun pe, Amin). Ilana Alufaa miiran si ti de. Kin ni? Njẹ a ni Urimu Tumimu loni? Bẹẹ ni. Ọrọ Ọlọrun ni. Isipaya kan, tabi ti o sọ ohunkohun tabi ẹkọ kan, ti o yatọ ti ko si ba gbogbo Bibeli mu, lati ibẹẹrẹ de opin gbogbo Iwe Mimo, o kuna.

Emi ko fẹẹ mọn, iru ijọ ẹlẹkọ-adamọ to ti wa, bi o se nse daradara to, bi o se jafafa to, bi o se mọwe to, o kuna.

116 Nigba ti ẹnikeni ba sọ nkan yii fun ọ ti a ti kọ wa nipa rẹ ni ile ijọsin yii, ti o si sọ fun ọ pe “Bi a ba bu omi fi wọn ọ dipo itẹbọmi, o ti dara to” O pa irọ fun ọ ni. Eyi ni ko ni tan imọlẹ pẹlu Urimu Tumimu ti ọjọ oni. Nigba ti o ba sọ fun ọ wi pe “ki a da omi le ọ lori ti dara to,” O pa irọ fun ọ ni. Bi o ba sọ fun ọ wi pe, “ Itẹbọmi ni Oruko Baba, Ọmọ, Ẹmi Mimọ dara,” O pa irọ fun ọ ni. Bi o ba sọ fun ọ wi pe, “ ko si isẹ Àrà mọ, o ti kọja” o pa irọ fun ọ ni. Bi o ba sọ fun ọ wi pe, “o dara ki obinrin waasu” o pa irọ fun ọ ni Bi o ba sọ fun ọ wi pe o dara ki iwọ faramọ ijọ-ẹlẹkọ-adamọ rẹ“ o pa irọ fun ọ ni. Ko nii tanna pẹlu Urimu Tumimu. Bẹẹ si ni ọpọlọpọ awọn ẹkọ ti o jade lati inu IYA AGBERE NLA” atijọ ni, ti o si farahan ninu awọn ijọ ti o ku wọnyii. Idi niyii ti a fi ta kete si gbogbo ijọ-ẹlẹkọ-adamọ.

117 A nifẹ awọn arakunrin ati arabinrin wa ninu gbogbo awọn ijọ-ẹlẹkọ-adamọ wọnyi sugbọn bi o ba lọ n sọ wi pe, “Mo jẹ Mẹtọdisti, eyi si sọ mi di kristẹni” Ni temi, iwọ jẹ kristẹni nitori pe a tun ọ bi nipa Ẹmi Ọlọrun. Iwọ ko ni lati jẹ Mẹtọdisti tabi Baptisti. Iwọ ko ni lati jẹ ikankan ninu wọn. Ohun kan soso nipe ki a tun ọ bi nipa Ẹmi Ọlọrun. Se o gba eyi gbọ bi? (Apejọpọ wi pe, “Aamin”)

Lori ipilẹ yii, bi ẹnikẹni ba fẹ fọwọ-sowọpọ pẹlu idapọ yii, ẹnikẹni to ba fẹ se itẹbọmi ni Oruko Jesu Kristi. Omi fun itẹbọmi niyii. Wọn yoo se itẹbọmi fun awọn eniyan lẹhin isẹju diẹ bayii. Bi ẹnikẹni ba si fẹ wa fun ohun miiran. Awa wa nibi. Otitọ ni.

118 Bayi, awa ko ni iwe ọmọ ijọ, ẹnikẹni ni o lee wa jọsin ninu ile isin yii. A gbagbọ pe Kristi wa ninu Ijọ Mẹtọdisti, Ijọ Baptisti, Ijọ Presibiteria. Ó ni awọn eniyan ninu gbogbo wọn. Ohun ti wọn se alaini loni, o jẹ nitori asọtẹlẹ eke to n mu awọn nkankan jade, ẹkọ awọn ijọ wọnyii, ti o lodi patapata si Bibeli.

Bayi bi o ba jẹ emi ni mo wa ninu isina wọnyii tẹlẹ, ti ẹnikan wa fi otitọ ye mi bi eleyi, mo gbagbọ pe, Ẹmi Ọlọrun wa to ninu mi lati wa inu Bibeli ki nsi pada wa se atunse. Bi mo ba kan lọ bọ oniwaasu lọwọ, ti mo kọ orukọ mi sinu iwe ọmọ ijọ kan, ti mo si ni ikorira ati arankan ni ọkan mi, ti mo si ni ilara ati ija, ti mo saigbagbọ pe Jesu Kristi jẹ Oluwosan Nla, abb. Emi yoo lọ se atunse pẹlu Ọlọrun ni kiakia. Dajudaju emi yoo se. Emi yoo se olootọ nipa rẹ. Emi yoo lọ se atunse pẹlu Ọlọrun. Bi mo ba kan se ẹsin nitoripe mo jẹ Baptisti tabi Mẹtọdisti, emi yoo lọ gba Ẹmi Kristi sinu ọkan mi. Emi yoo see. Bẹẹni.

119 Ranti isọji ti nbọ, ti yoo si bẹrẹ nipa ifẹ Ọlọrun ni alẹ Ọjọru ti nbọ yii. Lori ipilẹ yii ni. Fẹtisilẹ ẹyin ọrẹ, Ọlọrun Alàáyè tí Ó jẹ Òtítọ́ wà. Bẹẹ ni Jesu Kristi Ọmọ Ọlọrun Ẹmi Mimọ wa ninu Ijọ loni. Bayi, bi o ba se eniyan kan lo sọ iyẹn fun mi, mo ni ẹto lati se iyemeji si. Sugbọn fetisilẹ. Ni ọjọ kan, nigba ti mo jẹ ọmọkunrin kekere, mo duro labẹ igi kan. Mo ri I, mo gbọ Ti O sọ fun mi wi pe, “yẹra fun awọn obinrin oniwa ibajẹ wọn-

ọn-ni. Ma se mu siga. Mase sepe, tabi mu ọtin, ati gbogbo nkan wọnyii. Mo ni Isẹ kan fun ọ lati se nigba ti iwọ ba dagba". Mo mọn pe arigbamu, Ọlọrun Alaaye ni, ti o nsisẹ tọ Ọrọ Rẹ.

120 Nigba ti mo dagba diẹ si, bi O se ba mi pade, O si bami sọrọ. Mo ti ri I nibi kan, bi Ina ti on jo ninu igbo, ti Ina yẹn to n bì kiri. Mo ti gbọ ti O sọrọ, ohun ti yoo sẹlẹ gẹlẹ. Ni igba gbogbo, bẹẹ gẹlẹ lo se ma nsẹlẹ. Pépérépé bi O se sọ. Ẹni kan naa, to nsọ awọn isọtẹlẹ wọn-ọn-ni ti o nsẹlẹ rẹgi laikuna, Oun kan naa ni O n mi si mi lati kọ́ Bibeli yi bi mo se nkọ́ Ọ yii. Otitọ ni. Nitori naa, ọdọ Ọlọrun lo ti wa.

Ni temi, Ọlọrun Olodumare ni. O si jẹ Ọkan naa, lana, loni, ati titi lae. Jesu wipe,“ Mo wa lati Ọdọ Baba, mo si n pada sọdọ Baba nigba ti o wa…… Nigba ti o jẹ Ọlọrun ninu aginju, O jẹ Imọlẹ Ina to n jo. Awọn melo lo mọ yẹn (Apejopọ so pe "Aamin") O jẹ Ina to njo, Ọwọ Ina naa. O si wa si aye yii, wipe, "Emi wa lati ọdọ Baba Mi, Mo wa lati ọdọ Ọlọrun, Mo si tun n pada sọdọ Ọlọrun."

121 Nigba ti O ku, a sin-In, O jinde lẹẹkan si. Pọọlu si pade Rẹ ni ọna Damasiku. Kin ni O tun jẹ? (Ẹnikan wi pe, "Ọwọ Ina Kan") O jẹ Ọwọ Ina sibẹ. Bẹẹ ni. Kin ni O se nigba ti O wa laye? Kin ni O se nigba ti o pade Pọọlu? Bawo lo se ran ọn? O ran lọ sọdọ wolii kan to sọfun un bi yoo se se itẹbọmi, o sọ fun un ohun ti yoo se; o gbọwọ le e, o si wosan, o sọ fun pe o ti ri iran kan.

Jesu yii kan na wa nibi loni, ti o n se ohun kan naa, ti O si jẹ Ọwọ Ina sibẹ. O nkọ́ ohun kan naa, O si n fẹsẹ rẹ mulẹ nipa Ọrọ Rẹ, ati nipa isẹ amin ati isẹ ara. Mo layọ pupọ pe mo jẹ kristẹni. Emi ko mọn ohun miiran ti n ba se. Inu mi dun pe o jẹ Kristẹni.

122 Ẹyin ara ti ile ijọsin yii ti ẹ wa nibi, mo sọ fun yin pe, a oo yi orukọ yi pada ko tọ ki o maa jẹ ile isin Branham- Branham Tabanaku. Eniyan lasan ni yi. Se ẹ rii. A oo yi orukọ yi pada, a oo sọ ọ di orukọ miiran. A oo se eyii nigba to baya. Mo saa fẹ ki o jẹ Ijọ Ọlọrun Alaaye. Emi ko fẹ ki o jẹ Mẹtọdisti, Baptisti, Presibiteria, Pẹntikọsita. Gbogbo awọn eniyan wọn-ọn-ni ni mo fẹran pẹlu gbogbo ọkan mi. Emi ko mọn iyatọ kankan laarin wọn. Emi ko lee sọ iyatọ.

123 Mo saa nilati waasu ọrọ naa. Mo ju awọn, mo si faa. Ọpọlọ wa nibẹ, alantakun odo, ejo naa wa nibẹ, ati ẹja diẹ pẹlu. Ọlọrun nikan ni o lee sọ nipa iyẹn. Emi kan saa faa awọn ẹja ni. Mo waasu Ọrọ naaa, mo si fa àwọ̀n, mo wi pe, àwọn niyii Oluwa, wọn wa yika pẹpẹ. Iwọ mọn awọn Tirẹ. Iwọ ti mọn wọn lati ipilẹsẹ aye. Emi ko da ikankan mọn ninu wọn. Iwọ lo mọn wọn. Nitori naa, o ku si ọwọ Rẹ. Mo ti se ohun gbogbo ti mo lee se. Emi yo tun lọ ju àwọ̀n mi ni ibomiran bayii. Emi yoo tun ko awọn miiran jọ, gbogbo ohun ti mo le se niyi. O dara

Mo fẹ ma lọ ọ si le

Mo fẹ ma lọ ọ sile

Ile mi lọrun tán, O dara

Mo fẹ ma lọ ọ sile

124 Bayi ranti, bi ẹnikan ba fẹ ri mi, saa pe ọgbẹni Mercier nibi yii: BUtler 2-1519. (Nọmba ẹrọ ibanisọrọ yii ti yi pada). Inu wa yoo dun lati ri ọ. Bi awọn olufẹ rẹ ba wa, ti wọn si ni lati yara pada ni akoko awọn ipade isọji naa………. Bayii, emi nlọ lalẹ yii, lati lọ yara mi sọtọ, emi yoo lọ fun ọjọ meji sọdọ ara mi.

Emi a maa wọ inu ibẹ yẹn lati kẹkọ bi eleyi, "Oluwa, mo mọ pe iwọ wa nitosi. Mo mọ pe O wa nibi. Ọrọ rẹ si wi pe, 'Iwọ a maa sunmọn ẹni to ba sunmọ Ọ'. Emi yoo maa gbadura, n oo si maa fiye sii titi ti n oo fi ri Ọwọ Ina ni ti O bẹrẹ si sisẹ. Mo mọ pe, Oun ti se tan nigba naa. Emi yoo si bọ si ibi aga iwaasu fun isin iwosan lati gbadura ati lati se ohun ti mo ba lee se lati ran awọn alaisan ati alailokun lọwọ.

125 A mọn riri gbogbo aanu yin bayii. Nigba ti ẹ ba si de, ẹ wa pẹlu igbagbọ, a si ni ireti pe a o o ni awọn ipade to lagbara. Mo fẹ sọ iyẹn…... Arakunrin Jeffries, njẹ o wa nibi lalẹ yii? A fẹ mọn riri Arakunrin Jeffries ati isẹ rẹ. Mo ro pe, o ti pada lọ si erekusu.. abb. Inu mi dun lati ri Arakunrin ati arabinrin Wright ati ọpọlọpọ ẹyin eniyan nihin. Mo si ri amofin Robertson nihin laipẹ yii, o wọle laipẹ yii. Mo fẹ gboriyin fun un lori isẹ ti o gba ni ijelo. Ko si ẹni ti o sọ ẹni to jẹ. Ohun itiju ni yẹn. O si gba isẹ kan ti a jẹ fun un nipa isọtẹlẹ, ohun kan to fara jọ ohun ti mo ti n waasu lalẹ yii. Oniwaasu miiran kan wa nibi lowurọ yii, tabi lalẹ ana. Arakunrin Smith lati ijọ Mẹtọdisti tabi lati 'Ijọ ti Ọlọrun'. Emi ko mọn boya o wa nibi lalẹ yii tabi bẹẹ kọ. Bi o ba ti duro nibi aga iwaasu yii ri, ti o si wo ọhun ni, o soro lati sọ awọn eniyan ti o ri. Bi o ba wa nibi, Arakunrin Smith, a mọn riri rẹ.

126 Se kii se arakunrin wa lati Georgia lo joko sihin yii ni tosi Arakunrin Collins? (Arakunrin Neville sọ wi pe, "Bẹẹ ni") Inu mi dun lati tun ri ọ lalẹ yi arakunrin. Ẹyin to si ku, gbogbo yin, olukuluku eniyan mọn ẹni ti ẹ jẹ.

Mo gbagbọ pe, eyi ni arabinrin ati arakunrin to lọ gbadura fun ọmọbinrin naa nigba yẹn lo wa nihin yii. Dokita kan to joko si ẹgbẹ yii. Dokita, ki Ọlọrun bukun ọ.

127 Ẹ jọwọ, ẹ ma binu si mi ẹyin oniwaasu ati ẹyin ara mi, nitori pe mo kọ ẹkọ wọnyi kikan kikan bi mo se se yii. Ago ijọsin wa ni yii. Ohun ti a gbagbọ ni yii. A si gbe e kalẹ le ori Ọrọ Ọlọrun yii, ki a si mu ijọ yii gba A gbọ. Nigba naa, bi ẹ ba sina ni igbakugba, a oo le pada wa, a o si wi pe, “o mọn dara ju iyẹn lọ”. Ohun ni yii ninu ohun ti a gba silẹ, se orii? Ohun ni yii.

A ni ohun pupọ si ti o yẹ ki a gba silẹ nihin Leo. Sugbọn, ohun ti ẹ ti ri gba yii, ẹ duro tii gidi, a oo si gba eyi to ku laipẹ. Gẹgẹbi ọkunrin kan to n jẹ eso wọta-mẹlọọnu, o wi pe “Eyi ma dara pupọ o, sugbọn se a lee ri si? Nitori naa, a ni pupọ si ti a n mu bọ.

128 Ki Oluwa bukun yin, daradara. A oo ni isin itẹbọmi bayii. Se bẹẹ ni Arakunrin Neville? (Arakunrin Neville sọ pe, Bẹ ẹ ni, mo gbagbo pe beẹ ni) Se ẹnikan wa nihin ti o fẹ se itẹbọmi bayii? A ko fẹ mọn, ẹnikẹni ti iwọ lee jẹ, a wa nibi lati tẹ ọ bọmi. Ẹ na ọwọ soke, ẹyin ti ẹ fẹ se itẹbọmi. Ẹnikan, mo gbagbọ pe arabinrin kan ni yii. Se ẹlomiiran tun wa bi? Bayi, a ni asọ nihin fun ọkunrin ati obinrin.

129 Bayii, awa ko sọ fun ọ pe “fi ijọ Baptisti silẹ, fi Ijọ Mẹtọdisti silẹ, a ko sọ bẹẹ. Iwọ pada si ile isin rẹ. Sugbọn bi o ko ba tii se itẹbọmi ti o ba Iwe Mimọ mu, ni Orukọ Jesu….. kii se ni Orukọ Jesu lasan, Ni Orukọ ”Oluwa wa Jesu Kristi“. Iwe Mimọ ni yẹn. A ti tẹ ọ bọmi lọna to kuna.

Emi ko fẹ idaamu nigba ti mo ba de eti odo naa. Mo fẹ ki ohun gbogbo tọ́ bi mo ba se mọn mọ. Nigba ti mo ba mu iwe irinna mi lọwọ lati lee wọ ọkọ naa. Mo gba ọ niyanju ki iwọ naa se bẹẹ. Pada si ile isin rẹ. Iyẹn wa laarin iwọ ati Ọlọrun. Gbogbo ohun ti mo lee sọ fun ọ niyii. Sugbọn ko si ẹnikẹni ninu iwe Mimọ ti a tii tẹbọmi ni ọna miiran yatọ si Orukọ 'Oluwa wa Jesu Kristi'. Awọn ti wọn si ti se itẹbọmi lọna miiran, Pọọlu pasẹ fun wọn ki a tun wọn tẹbọmi ni Orukọ Oluwa wa Jesu Kristi. Bẹẹ ni, o se bẹẹ. Ohun ti o si se, o pasẹ fun wa lati se bẹẹ. Ohun ti ao se niyii, nipa ifẹ Ọlọrun.

130 A gbagbọ ninu wiwẹ ẹsẹ ara. A gbagbọ ninu onjẹ alẹ Oluwa. A gbagbọ ninu ipadabọ Jesu Kristi nigba keji ninu agọ Ara Oluwa ti a foju ri. Kii se nipa ẹmi sugbọn Agọ Ara Jesu Kristi ti O n pada bọ ninu Ogo. A gbagbọ ninu ajinde awọn oku lati gba agọ ara, kii se ara ogbo to ti hunjọ nigba ti a nlọ sinu iboji. Sugbọn ara tuntun ninu ipo ọdọ to dara julọ lati wa laaye ni ọdọ titi Ainipẹkun. A gbagbọ ninu aiku fun ọkan patapata. A gbagbọ pe Iru Iye Ainipẹkun kan soso ni o wa, eyi si ni Iye ti a n ri gba lati ọdọ Jesu Kristi. Otitọ ni yii. Nitori naa, a ko gbagbọ ninu ijiya ainipẹkun. A gbagbọ ninu ina ọrun apaadi, to n jo pẹlu sufuru. Sugbọn a ko gbagbọ pe o njo titi ainipẹkun. Bi o ba se bẹẹ-ni, ni iye Ainipẹkun.

Iye Ainipẹkun kan lo wa, ọdọ Ọlọrun ni o si ti n wa. Iwọ yoo jona fun, boya miliọnu ọdun boya million mẹwa, emi ko mọn, sugbọn iwọ ko lee ni iye Ainipẹkun. O ko lee jona fun ainipẹkun. O lee jona titi lae, sugbọn kii se fun ainipẹkun. Iyatọ wa laarin ainipẹkun ati titi lae. Titi lae wa fun lae ati lae lae. O jasi 'fun saa kan'. Sugbọn ainipẹkun…. Iwọ ko lee ni ijiya ainipẹkun, iwọ lee ni Iye Ainipẹkun nitori orisi Iye Ainipẹkun kan ni o wa. Ẹni ti o ba si ni Iye Ainipẹkun, o wa laaye, Ọlọrun si bukun un titi lae. Sugbọn ọkàn ti o ba sẹ̀, ọkan naa yoo se kin-ni? Yoo kú. Nigba naa, oun ko ni iye Ainipẹkun. Dajudaju ko nii. Yoo ni ijiya rẹ sugbọn ko ni iye Ainipẹkun. Ẹ rii, wi pe, ọpọlọpọ nkan loku ti a ko tii kọ, a oo see boba ya. Ki Oluwa bukun yin.

131 Bayi, ẹ jẹ ki a kọrin atijọ to dara yii, nigba ti arabinrin lọ si ibi ti yoo ti gbara-di. Mo gbagbọ pe obinrin yii…… Rosella, se iya rẹ ni yẹn? Họwu! ki Ọlọrun bukun ọkan rẹ. Inu mi dun arabinrin fun eyi ti o n se yii. Iyẹn dara pupọ.

Rosella Griffin, ọkan lara awọn ọrẹ to dara julọ ti a ni. Oun ni ọdọbinrin ti o jẹ amutinpara. O lee jẹ ajeji si diẹ ninu ẹyin to wa nibi, Rosella ko bikita pe mo sọ ohun ti mo sọ yii. Nigba ti o wa si iwaju ni Indiana, iwọ ko tii ri ẹniti o jẹ ẹni are bẹẹ ri, ẹni ti ọtin amupara ti sọ di idakuda. Awọn Dokita mẹrin to lorukọ ni Chicago ti paa ti. Wọn wi pe awọn to ntọju awọn alamu-para-lati-mu-wọn-pada-bọ-sipo ti tuuba lorii rẹ. Sugbọn ni alẹ ọjọ kan, nigba ti o wa si ipade kan, Ẹmi Mimọ tan imọlẹ si aye rẹ. O sọ igbe aye rẹ fun un, iyẹn si pari isoro rẹ. Ẹ woo nisisiyi, mo gba wipe o ti le ni ọgbọn ọdun, sibẹ eniyan lee ro wi pe, ko tii ju ọdun mejidinlogun. Obinrin to jẹ ọdọ to dun wo, ti o si rẹwa. Ko tii fi ẹnu kan ọtin lile lati igba naa. Ko ni ifẹ si mọn, o n gbe igbe aye rẹ fun Kristi, o n lọ kakiri nibi gbogbo, o n jẹri si Ogo Ọlọrun fun awọn ẹlẹsẹ, ati awọn ọmutin, ati laarin awọn ti wọn n gbiyanju lati bori iwa buburu abb ni gbogbo Chicago, o n se ohun kan fun Oluwa. O ti se itẹbọmi ni Orukọ Oluwa wa Jesu Kristi. Iya rẹ si wa lalẹ yii lati se bẹẹ pẹlu. Bi Ọlọrun ba lee woo san, bi Jesu ba le woo san……..

132 Ohunkohun ti iwọ ba n se, maa see ni Orukọ Jesu. Ohun ti Bibeli wi ni yii. Bẹẹ ni. O dara. Bayi, a oo ni isin itẹbọmi. A oo pa ina inu gbongan fun iseju diẹ, nigba ti a n pese silẹ fun isin itẹbọmi. Lẹhin naa, a nreti akoko to dara niwaju Oluwa. Se ẹ oo…… O dara. O san ki ẹ tete mura silẹ bayii. Emi yoo bẹrẹ sii dari orin abb nigbati a n tẹ siwaju. Se awọn asọ itẹbọmi wa? Doc, kiakia. O dara. Ẹ jẹ ki a kọ ọkan ninu awọn orin atijọ to dara yii. (Idakẹ kukuru ninu ohun ti a gba silẹ) titi a o fi se iyẹn bi a ti n lọ. A gbọdọ se kin ni?

Saa di Oruko Jesu mu

Jẹ ka wọlẹ lẹsẹ Rẹ

Ọba'wọn Ọba, ao de lade

Gba t'ajo wa ba pari

O dara, e dide duro lẹsẹ yin

Saa di Orukọ Jesu mu

Nigba ibanujẹ rẹ

Yo si fi itunu fun ọ

Yoo fi itunu ọ (Mo sọ fun ọ ohun ti mo fẹ ka se bayi, yi oju pada ki o sibọ ọwọ pẹlu ẹnikan nibẹ ki o wipe, “ba wo ni, arakunrin? Inu mi dun lati wa ninu isin”)

Orukọ….. Yebiye

Ireti wa laye yi

Orukọ…… Yebiye

Ayọ fun awọn tọrun.

Ìwàásù lati ẹnu

William Marrion Branham

"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7

www.messagehub.info